**COURSE GUIDE**

# YOR 217
# IṢẸ́ ÀWỌN YORÙBÁ NÍ AYÉ ÀTIJỌ́ ÀTI LÓDE-ÒNÍ
# (THE YORUBA TRADITIONAL AND CONTEMPORARY PROFESSIONS)


**Láti Ọwọ́** Dr Olubunmi Okeowo Femi-Amao (Course Writer )-NOUN

Professor Moses Olufunmilayo Olateju (Course Editor )-NOUN


**NATIONAL OPEN UNIVERSTIY OF NIGERIA**

© 2023 by NOUN Press National
Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone,
Nnamdi Azikwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

Printed 2009, 2023

ISBN: 978-978-058 -410-0

Reviewed 2021

## COURSE TITLE : IṢẸ́ ÀWỌN YORÙBÁ NÍ AYÉ ÀTIJỌ́ ÀTI LÓDE-ÒNÍ

## COURSE CONTENT SPECIFICATIONS (COURSE DESCRIPTION)

Yorùbá culture has a rich heritage of traditional and contemporary professions. Traditional professions often reflect the cultural and hisorical practices of the Yoruba while contemporary professions encompass modern occupations. This course is all about getting insight into various Yorùbá professions and how they can be useful in our contemporary society.

## ÌFÁÁRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Orúkọ kọ́ọ̀sì yìí ni YOR 217:Àwọn Iṣẹ́ Yorùbá ní Ayé Àtijọ́ àti lóde-òní. Kọ́ọ̀sì yìí jẹ́ ọ̀kanpàtàkì nínú àwọn ẹ̀kọ́ tí o ní láti kọ́ látigbaoyè ìjìnlẹ̀ àkọ́kọ́ nínú èdè Yorùbá, ìdá méta péré ni kọ́ọ̀sì náà sì kó nínú àpapọ̀ gbogbo kọ́ọ̀sì tí o máa dáwọ́lé.

Ohun tí kọ́ọ̀sì yìí dá lé niàwọn iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá. Ní kúkurú, kọ́ọ̀sì yìí níí ṣe pẹ̀lú kíkọ́, mímọ̀ àti ṣíṣe àmúlò àwọn iṣẹ́Yorùbáníbikíbi, àyèkáyè tàbí ipòkípò tí o bá bá ara rẹ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́gboyètàbí onímọ̀ nínú èdè Yorùbá. Nípa ìdí èyí, ìyànjú tí kọ́ọ̀sì yìí ń gbà niláti sọ ọ́ di ẹni tí ó ní iṣẹ́ kan tàbí méjì tí o lè fi ṣe ọrọ̀-ajé, tí ó sì lè mú kí o di ẹni àyèsi ní àwùjọ.

Lẹ́yìn tí o bá gbaìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, ìwọ yóò di ẹni tí ó lè dá dúró láàyè ara rẹ gẹ́gẹ́ bí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ó ní iṣẹ́ tí ó yàn láàyò, tí ó sì jẹ́ ọ̀gá iṣẹ́ tí ó kó àwon ènìyàn sábẹ́, láti fún wọn ní iṣẹ́ oúnjẹ òòjọ́ wọn nípasẹ̀ iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe fún ọ.

Báyìí, ìmọ̀ràn mi fún ọ ni kí o ka ìwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí dáadáaní àkàtúnkà, kí ó yé ọ yékéyéké, kí o má sì gbàgbé lát imáa ṣe àmúlò gbogbo àbá, ìmọ̀ràn àti ìtọ́ni tí a pe àkíyèsí rẹ sí nínú ìwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àṣeyè ni alákàn í í ṣepo, àṣeyè lo máa ṣe lágbára Ọlọ́run, yóò sì jú ọ ṣe o.

## ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Vice Chancellor’s message
Foreword
Àkóónú
**MÓDÙ KÌÍNÍ: ÀLÀYÉ IṢẸ́ ṢÍṢE NÍ ILẸ̀ YORÙBÁ**
**ÌpínKìíní: Iṣẹ́ àti àǹfààní iṣẹ́**
1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àtiÀfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Iṣẹ́ àti àǹfààní iṣẹ́
**4.2 Ìpín Kejì:**
4.2.1 Iṣẹ́ Kíkọ́ ní ààrín àwọn Yorùbá
4.2.2 Yíya iṣẹ́
**4.3 ÌpínKẹta: Iṣẹ́ tí àwọ́n Yorùbá ń ṣe**
4.3.1 Ìfáárà sí iṣẹ́ ṣiṣe ní ilẹ̀ Yorùbá
4.3.2 Àkíyèsí
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
**MÓDÙ KEJÌ: ÀWỌN IṢẸ́ ÌṢẸ̀ǸBÁYÉ ILẸ̀ YORÙBÁ APÁ KÌÍNÍ**
1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àtiÀfojúsùn

3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1 ÌpínKìíní: Iṣẹ́ Àgbẹ̀**
4.1.1 Àlàyé lórí iṣẹ́ Àgbẹ̀ àti àǹfààní iṣẹ́ àgbẹ̀
**4.2 Ìpín Kejì: Iṣẹ́ Ọdẹ**
4.2.1 Àlàyé lórí iṣẹ́ Ọdẹ àti àǹfààní iṣẹ́ ọdẹ
4.2.2 Èdè Àmúlò Iṣẹ́ Ọdẹ
**4.3 ÌpínKẹta: Iṣẹ́ ọnà**
4.3.1 Àlàyé lóri iṣẹ́ ọnà
4.3.1.1 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Iṣẹ́ Ọnà
**MÓDÙ KẸTA: ÀWỌN IṢẸ́ ÌṢẸ̀ǸBÁYÉ ILẸ̀ YORÙBÁ APÁ KEJÌ**
1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1 Ìpín Kìíní: Iṣẹ́ Ẹbu**
4.1.1 Epo pupa fífọ̀
4.1.2 Àkíyèsí
4.1.3 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Epo Fífọ̀
**4.2 Ìpín Kejì:**
4.2.1 Yànkò tàbí Àdí
4.2.2 Òrí Kíkọ
4.2.3 Aró Dídá
4.2.3.1 Bí a ṣe ń ṣe Lábúlábú
**4.3 ÌpínKẹta:**
**4.3.1** Iṣẹ́ Irin Sísun
4.3.1.2 **E**dè Àmúlò iṣẹ́ Irin sísun
4.3.2 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ/ Arọ́
4.3.2.1 Èdè Àmúlò fún iṣẹ́ Arọ́
4.3.3 Aṣọ Òfì Híhun
4.3.3.1 Èdè Àmúlò inú Aṣọ Òfì híhun
**4.4 Ìpín Kẹrin:**
4.4.1 Irú Fífọ̀
4.4.1.1 Àkíyèsí
4.4.1.2 Díẹ̀ lára Èdé Àmúlò Irú Fífọ̀
4.4.2 Ọtí pípọn
4.4.2.1 Ọtí Àgàdàgídí
4.4.2.2 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Ọtí Pípọn
**4.5 Ìpín Karùn-ún:**
4.5.1 Ìkòkò Mímọ
4.5.2 Àkíyèsí
4.5.2.1 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Ìkòkò Mímọ
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

**MÓDÙ KẸRIN: IṢẸ́ YORÙBÁ** NÍ AYÉ ÒDE-ÒNÍ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1 Ìpín Kìíní: Olùkọ́**
4.1.1 Iṣẹ́ Olùkọ́
**4.2 Ìpín Kejì:**
4.2.1 Olúyoko
4.2.2 Alága Ìgbéyàwó
**4.3 Ìpín Kẹta:**
4.3.1 Ògbufọ̀
4.3.2 Akàròyìn
4.3.3 Òṣèré Orí Ìtàgé
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ

Ohun tó jẹ́ àfojúsùn kọ́ọ̀sì yìí gan-an ni láti sọ ọ́ di Adánúrò-dáhunṣe, ẹni tí ó lè dá dúró gẹ́gẹ́ bí ọ̀gá iṣẹ́ láàyè ara rẹ, tí yóò si jẹ́ olùpèsè iṣẹ́ fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ènìyàn, nípasẹ̀ ìmọ̀ tí o ní nínú kọ́ọ̀sì yìí. Èyí ni pé, ìwọ kò nílò láti ṣèṣẹ̀ máa wá iṣẹ́ kiri mọ́ lẹ́yìn tí o bá ti kẹ́kọ̀ọ́ yege nínú kọ́ọ̀sì yìí, nítorí ìwọ yóò ti ní òye iṣẹ Yorùbá lọ́kan-ò-jọ̀kan tí o lè dáwọ́lé, tí ó sì lè pèsè owó àti ìgbé ayé ìrọ̀rùn fún ọ. Kí èròǹgbà àti àfojúsùn yìí lè rí bí a ti fẹ́ kí ó rí fún ọ, a ti pín àkóónú kọ́ọ̀sì yìí sí Módù mẹ́rin tó wà ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé. Ẹ̀kọ́ inú àwọn Módù mẹ́rẹ̀ẹ̀rin wọnú ara wọn. Lẹ́yìn tí o bá sì ti kà wọ́n tán dáadáa ní àkàtúnkà, àwọn ohun dáradára tó máa ṣẹlẹ̀ sí ọ nìwọ̀nyí:

(i) Ìwọ yóò ní ọgbọ́n ìmọ̀ọ́nṣe láti dá iṣẹ́ ti ara rẹ sílẹ̀ ní ibikíbi lágbàáyé.
(ii) Ìwọ yóò ní ìmọ̀ láti kọ́ ni ní àwọn iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá tí o bá yàn láàyò. Pẹ̀lú gbogbo atótónu tí a ti ṣe yìí, ó di dandan kí ọ̀rọ̀ rẹ rí bí a ti fẹ́ kó rí fún ọ gẹ́lẹ́. Ẹ̀rín yóò sì gba ẹ̀rẹ̀kẹ́ tàbí ẹnu wa nígbà tí ìwọ bá yege nínú ìdánwò rẹ, tí o sì nímọ̀ kíkún lórí–
àwọn iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá.
Àṣeyè la ó ṣe o, Àṣẹẹẹ........

## OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́

Kí èròǹgbà àti àfojúsùn wa fún ọ ba à wá sí ìmúṣẹ, ojúṣe rẹ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ ni kí o rí i pé o wá àyè láti ka àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a gbé kalẹ̀ fún ọ yìí. A pín àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà sí módù mẹ́rin (4), tí módù kọ̀ọ̀kan sì tún pín sí ìpín bíi mélòó kan. Yóò gbà ọ́ tó ọ̀sẹ̀ bíi mélòó kan láti ka módù mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tó wà nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. nínú rẹ̀, àwọn ìbéèrè ìṣaájú wà níbẹ̀

láti tọ́ ọ sọ́nà àti láti fún ọ ní òye ohun tí o máa bá pàdé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́. Lẹ́yìn èyí ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gan-an yóò ṣẹ̀ṣẹ̀ wáyé.

A ti pín àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà sí ìpín-ìpín kí wọ́n má ba à tètè sú ọ. Ojúṣe rẹ ni láti kà wọ́n ní àkàyé àti àkàtúnkà. Bí o bá rí ohun tí kò fi bẹ́ẹ̀ yé ọ tó, àǹfààní yóò wà fún ọ láti fojúrinjú pẹ̀lú olùkọ́ nínú ètò tí àwọnAláṣẹ Fásitì yóò gbé kalẹ̀ fún ìfarakínra pẹ̀lú olùkọ́ tàbí nípa bíbá olùkọ́ sọ̀rọ̀ lórí aago tàbí ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá. Yóò ṣeé ṣe o. Àmí-àṣẹ.

## ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Oríṣìí ọ̀nà ìgbéléwọ̀n méjì ló wà. Ìkínní ni iṣẹ́ ṣíṣe tàbí iṣẹ́ àmúṣe èyí tó kó ìdá ọgbọ̀n (30%) nínú ọgọ́rùn-ún. Ìkejì ni ìdánwò, èyí tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò jókòó ṣe lẹ́yìn tí o bá ti gba ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tán. Ìdá àádọ́rin (70%) nínú ọgọ́rùn-ún ni ìdánwò yìí.

## ÌGBÉLÉWỌ̀N TÍ OLÙKỌ́ YÓÒ MÁÀKÌ

Módù mẹ́rin (4) ló wà nínú kọ́ọ̀sì yìí, iṣẹ́ ṣíṣe (iṣẹ́ àmúṣe) sì wà ní òpin módù kọ̀ọ̀kan. Akẹ́kọ̀ọ́ yóò mú ìbéèrè mẹ́ta mẹ́ta nínú àwọn ìbéèrè tó wà lábẹ́ iṣẹ́ ṣíṣe, yóò ṣe àkọsílẹ̀ ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè mẹ́ta náà, èyí tí yóò fi ṣọwọ́ sí olùkọ́ láti máàkì. Ó ṣeéṣe kí ó jẹ́ pé ọjọ́ ìdánwò ni àwọn iṣẹ́ ṣíṣe yóò di gbígbàjọ fún olùkọ́ láti máàkì. Má ṣe gbàgbé pé ìdá ọgbọ̀n péré (30%) nínú ọgọ́rùn-ún ni máàkì fún iṣẹ́ àmúrelé.

## ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ

Èyí ni ìdánwò tí o ó jókòó ṣe lẹ́yìn tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ bá ti parí. Àwọn aláṣẹ ilé-ẹ̀kọ́ ni yóò kéde ọjọ́, àsìkò àti ibi tí ìdánwò náà yóò ti wáyé. Má ṣe gbàgbé pé ìdá àádọ́rin (70%) ni ìdánwò yìí kó nínú ọgọ́rùn-ún.

## ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn bí máàkì gbígbà yóò ṣe rí.

| Ìgbéléwọ̀n | Máàkì |
|---|---|
| Iṣẹ́-ṣíṣe/Àmúṣemódù 1 – 4 | Ọgbọ̀n (30%) |
| Ìdánwò Àṣekágbá | Àádọ́rin (70%) |
| Àpapọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

# MÓDÙ KÌÍNÍ: ÀLÀYÉ IṢẸ́ ṢÍṢE NÍ ILẸ̀ YORÙBÁ

## Ìpín Kìíní: Iṣẹ́ àti Àǹfààní Iṣẹ́

## 1.0 Ìfáárà

Ní Módù yìí, ohun tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ dálé ni pàtàkì àti àǹfààní iṣẹ́ ní àwùjọ Yorùbá. Àwọn babańlá wa ṣe àpọ́nlé iṣẹ́ púpọ̀, wọn a sì máa ṣe ìkìlọ̀ pé, kí èèyàn má fi ààrọ̀ ṣeré nítorí kí ó má ba à jìyà lọ́jọ́ alẹ́. Àwọn òbí wa mọ̀ pé èrè ńlá wà fún ẹni tí ó bá tẹra mọ́ṣẹ́ lọ́jọ́ alẹ́.. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ yóò kà nípa ohun tí iṣẹ́ jẹ́ àti àǹfààní rẹ̀. Bákan náà, o ó máa kà nípa iṣẹ́ kíkọ́, yíya iṣẹ́ àti onírúurú iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá

**Èròǹgbà àtiÀfojúsùn**
Lẹ́yìn tí o bá ti ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, ìwọ yóò ní ìmọ̀ kíkún lórí ohun tí iṣẹ́ jẹ́ àti àwọn àǹfààní tí ó wà nínú iṣẹ́ àṣekára. Gẹ́gẹ́ bí àfojúsùn, òye ọwọ́ tí Yorùbá fi mú iṣẹ àti ìgbàgbọ́ wọn nípa iṣẹ́ yóò yé ọ yékéyéké. Bákan náà, ìwọ yóò lè mọ àǹfààní tí ó wà nínú iṣẹ́ ṣíṣe

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

- Ṣàlàyé ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ nípa iṣẹ́
- Sọ díẹ̀ lára àǹfààní iṣẹ́ ṣiṣe?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Iṣẹ́ àti àǹfààní iṣẹ́

Ká jí ká ṣiṣẹ́ jẹ́ ohun tí àwọn Yorùbá mú ní pàtàkì. Àwọn Ìṣẹ̀run wa fẹ́ràn àtiṣiṣẹ́ tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ tí wọ́n fi ní ìgbàgbọ́ pé, ìwà ọ̀lẹ àti òròjú máa ń fa àrùn sí alàìfẹ́ṣẹ́ẹ̀ṣe lára. Wọ́n máa ń pe ẹni tí kò fẹ́ ṣiṣẹ́ ní 'Ọ̀lẹ́dàrùn'. Yorùbá gbàgbọ́ pé iṣẹ́ làá ṣe tí a fi ń jàre òṣì, èyí ni pé wọ́n ní ìgbàgbọ́ pé iṣẹ́ ni òògùn ìṣẹ́, wọ́n máa ń sọ pé ẹni tí ìṣẹ́ ń ṣẹ́ kó má bỌ̀ṣun, ọ̀ràn kò kan tÒòṣà, ò báà bọ̀rìṣà, kó o bọ Ọbàtálá, ó dijọ́ tí o bá ṣiṣẹ́ ajé kí o tó jẹun.

Wọn tún máa ń sọ pé "Iṣẹ́ ni ọmọ àṣeję, òwò ni ọmọ àṣelà", èyí túmọ̀ sí pé, kí ènìyàn tó rí ọwọ́ mú lọ sẹ́nu, kí ènìyàn sì tó di ọlọ́là láyé, ènìyàn ní láti ṣiṣẹ́. Bákan náà, Yorùbá gbàgbọ́ pé, ìgbà ààrọ̀ ẹ̀dá láyé ni àsìkò tí ẹ̀dá gbọ́dọ̀ fi ṣiṣẹ́, ẹni tí ó bá fi ààrọ̀ ṣeré yóò jìyà lọ́jọ́ alẹ́.Wọ́n máa ń sọ pé "Àgbà tó bá fewú rẹrù tó tún fà ọ̀kan dání, ti fi ààrọ̀ ṣeré ni", tàbí kí wọ́n sọ pé " Àgbà tó bá fààrọ̀ ṣeré, yóó fọ̀sán pòṣé, yóó falẹ́ sunkún ni". Àwọn àlàyé tí a ṣe yìí ti fihàn pé ìran Yorùbá fẹ́ràn iṣẹ́ ṣíṣe, wọn kìí ṣe ọ̀lẹ, wọ́n kórìíra ìmẹ́lẹ́, wọ́n sì ti fi àtubọ̀tán ìwà ọ̀lẹ hàn , ìwọ pẹ̀lú sì ti rí i dáju pé kò sí ààyè fún ọ̀lẹ ní ààrín àwọn Yorùbá.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú pé èrè wà fún ẹni tí ó bá ṣiṣẹ́, àwọn àǹfààní iṣẹ́ àṣekára pọ̀ , ṣùgbọ́n a ó mẹ́nu ba díẹ̀ nínú wọn.

**Àǹfààní Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Ó máa ń sọ ènìyàn di ọlọ́lá.
2. Ó máa ń jẹ́ kí ẹnu ènìyàn tólẹ̀ láti sọ̀rọ̀ láàárín ẹgbẹ́ àti ọ̀gbà
3. Ó máa ń jẹ́ kí ọgbọ́n ìmò-ọ́n-ṣe ènìyàn dàgbà, kí ó sì dára sí i. Àpẹẹrẹ tí ènìyàn bá ń hun aṣọ tàbí ẹní, nítorí ó ń ṣe iṣẹ́ náà ní gbogbo ìgbà yóò jẹ́ kí ó máa mọ̀-ọ́n ṣe sí i, yóò sì ní òye iṣẹ́ náà ju ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ lọ
4. Ó máa ń ran ènìyàn lọ́wọ́ láti ní òye ohun tuntun tí yóó mú kí iṣẹ́ tèsíwájú
5. Ó máa ń gbé ẹbí ró. Èyí túmọ̀ sí pé, yóòjẹ kí iyì wà fún ọkọ lọ́dọ̀ aya, nítorí ọkọ yóò lè ṣe ojúṣe rẹ̀ déédé, bákan náà, iyì yóò wà fún aya lọ́dọ̀ ọkọ, nítorí yóò lè ran ọkọ lọ́wọ́ nígbà tí ó bá fẹ́ kù díẹ̀ káàtó, nítorí àwọn méjèèjì kìí ṣe ọ̀lẹ, àwọn ọmọ wọn pẹ̀lú yóó lè rí àwọn òbí wọn gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ àwòkọ́ṣe rere fún ọjọ́ iwájú wọn.

## 4.2 Ìpín Kejì

### 4.2.1 Iṣẹ́ Kíkọ́ ní Àárín Àwọn Yorùbá

Bí a bá ń wo ètò ìkọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ àwọnYorùbá yóò ya ni lẹ́nu díẹ̀ nítorí pé bí a bá fi wé tòde òní a ó rí i pé kò sí ètò kan tó gbóòrò tí ó kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pọ̀ gẹ́gẹ bí ọ̀làjú ti mú un wá fún wa lóde òní. Èké ti dáyé, aásà tid'Ápòmù, gbogbonǹkan ló ti yàtọ̀ sí ayé àtijọ́. Síbẹ̀síbẹ̀ a rí i pé ètò tó wà láàrin àwọnYorùbá jẹ́ ètò tó fìdí múlẹ̀, nítòótọ́ kò gbòòrò láti kó ọ̀pọlọpọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pọ̀.

A lè pín ètò ìkọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ yìí sí bí ọ̀nà mẹ́rin, èyí tó gbòòrò jù nínú àwọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ni **àjẹbí** tàbí **àdáyéba**. Èyí ni pé kí ọmọ jogún ohun tí baba ń ṣe, kí baba fiṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe lé ọmọ lọ́wọ́. Èyí ló dà bí ẹni pé ó gbòòrò jù nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ tí a ń ṣe bíi iṣẹ́ àgbẹ̀, bí alágbẹ̀dẹ Ògún, bí àwọn tó ń hunṣọ tàbí àwọn tí wọ́n ń lù ìlù. A ó rí i pé iṣẹ́ ìdílé ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn, tó jẹ́ pé nígbà tí baba bá ti wà láyé tí ó ń ṣiṣẹ́ yìí náà ni ọmọ yóò máa wo ọwọ́ọ rẹ̀, ibẹ̀ náà ni òun náà yóò sì timáa kọ́ ẹ̀kọ́. Irú eléyìí ló sì dárajù nítorí pé kò sí pé à ń dájọ́ sí iye àkókò tí ọmọ náà yóò lò fún ẹ̀kọ́sẹ́, ṣùgbọ́n yóòti bẹ̀rẹ̀¸láti kékeré, kò sì tó yaiṣẹ́ lọ́dọ̀ọ baba rè, yóò ti di àgbàlagbà, ọkàn rẹ̀ yóò sì ti balẹ̀ sí iṣẹ́ náà ní ṣíṣe. A ó wàá ríi pé ṣàṣà niiṣẹ́ tí a kò lè kọ́ ní ọ̀nà yìí. Gbogbo iṣẹ́ tí Yorùbá sí ń ṣe ló ṣe é fi lé ọmọ lọ́wọ́ àfi àwọn iṣẹ́ tí a wá ń ṣe nísisìyí tí àwọn ènìyàn yóò máa sọ pé kò ṣe é fi lé ọmọ lọ́wọ́.

Ọ̀nà kejì tí àwọnYorùbá tún ń gbà kọ́sẹ́ ni ìpilẹ̀kọ èyí ni àwọn mìíràn máa ń pè ní '**Àwọ̀ṣe**' èyí ni pé ní ìdílé kan a kì í ṣe irú iṣẹ́ tí ọmọ fẹ́ kọ́

bóyá iṣẹ́ awo ṣíṣe tí kò sí ní ìdílé wọn, nǹkan kan tí irú ẹni tó bá fẹ́ kọ́ irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ lè ṣeni pé kí olúwarẹ̀ wá ẹni tó bá ń ṣeiṣẹ́ náà kí a sì fi ọmọ náà sí i lọ́dọ̀ láti máa kọ́ iṣẹ́. Ọ̀gá iṣẹ́ àti onídùúró ọmọ iṣẹ́ yóò ṣe ìpinnu iye àkókò tó máa lò àti iye tí ó maa gbà tó bá fẹ́ gba owó lọ́wọ́ ọmọ iṣẹ́ náà àti gbogbo òfin tí ọ̀gá iṣẹ́ máa fún un tí ó máa tẹ̀lé nígbà tí ó bá wà lọ́dọ̀ọ rẹ̀. èyí ló si pọ̀jù lóde òní.

Ọ̀pọ̀lọpọ ọmọ ni kò mọ iṣẹ́ ìdílé wọn mọ́. Òmíràn tí ó jẹ́ ọmọ onílù kò mọ ènìyàn kì, òmíràn tí ó jẹ́ ọmọ ahunṣọ ni ò mọ aṣọ hun.

Ọ̀nà kẹtanièyí tí a lè pè ní '**Ìsínjẹ**' tàbí '**àwòṣe**' èyí ni kí ẹnìkan fẹ́ràn iṣẹ́ kan tí wọ́n kì í ṣe ní ìdílé rẹ̀, pàápàá tí ó bá ti dàgbà jù irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ ní kíkọ́ lọ, ó lè wá máa dá ọgbọ́n inú láti mú ẹni tó ń ṣe irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ lọ́rẹ̀ẹ́. Yóo máa wò ó bí ó ti ń ṣe iṣẹ́ náà láìjẹ kí onísẹ́ fura pé ó ń fi ọgbọ́n inú kọ́ iṣẹ́ náà, bí ó bá sì délé yóò lọ máa dán an wò ní kọ̀rọ̀, yóò máa ṣe é báyìí títí yóò fi mọ́ ọ lọ́wọ́ gidi láìṣe pé ó kọ́ iṣẹ́ náà gidi lọ́wọ́ ẹnìkan. Èyí wọ́pọ̀ lọ́dọ̀ àwọn alágbe. Ọ̀nà yìí pọ̀ láàrin àwọn tó bá ti dàgbà tí wọ́n sì fẹ́ mọ iṣẹ́. Èyí ni ọ̀nà kẹta tí à ń gbà láti kọ́ iṣẹ́.

Ọ̀na kẹrin tí à ń gbà ni ti Ìwọ̀fà. Àwọn iṣẹ́ kan wà tó ṣòro láti kọ́, tí àwọn tí wọ́n mọ̀ ọ́n kì í fẹ́ kọ́ ni, bí iṣẹ́ ìṣègùn àti ti adáhunṣe. Bí ó bá jẹ́ ọmọ tí wọ́n sì fẹ́ràn, wọn kò ní fidí gbogbo nǹkan hàn án. Bí ó bá sì jẹ́ ọmọ tí ó ni ìkà gidi, wọn kò ní fi nǹkankan hàn án. Wọn yóò sọ pé yóò ba ìdílé wọn jẹ́. Ṣùgbọ́n ká sọ pé kò sí adáhunṣe ní ìdílé ẹnìkan tí olúwa rẹ̀ sì fẹ́ kọ́ irú iṣẹ́ báyìí, bí bàbá rẹ̀ bá mú un lọ pé kí wọ́n bá òun kọ́ ọ ní iṣẹ́ yìí àwọn adáhunṣe lè sọ pé kí wọ́n lọ ní sùúrù ná, pé tó bá yá wọn yóò ránṣẹ́ sí wọn àti pé wọn kò tí ì fẹ́ ọmọọṣẹ́ ní lọ́ọ́lọ́ọ́ yìí. Wọn kò ní fẹ́ kọ́ ọ, tàbí bí ó tilẹ̀ wá lọ́dọ̀ wọn, wọ́n lè má fi iṣẹ́ hàn án déédéé. Bí bàbá ọmọ yìí bá gbọ́n ó lè lọ yáwó lọ́dọ̀ onísègùn tàbí adáhunṣe kan kí ó sì sọ pé ọmọ náà ni òun fe fi ṣe "Ọfà', irú ọgbọ́n báyìí ni wọ́n lè fi fi ọmọ sí ọ̀dọ̀ irú àwọn bẹ́ẹ̀ láti máa kọ́ṣẹ́. Ibi tí wọ́n bá ti ń rán an nísẹ́ kiri ni ọmọ náà yóò ti máa fi ojú sí gbogbo nǹkan tí yóò sì máa fi ọgbọ́n inú wò bí ọ̀gá rẹ̀ bá ti ṣe ń ṣe egbòogi fún ni. Ìgbà tí bàbá ọmọ yìí bá rí i pé ọmọ ti mọṣẹ́ dáradára tí ó sì lè dá dúró, yóò wá wá owó tí ó yá lọ́wọ́ onísègùn láti wá fi dúpẹ́, àti pé kí ọmọ tí ń ṣe ọfà lè wálé. Ó ṣe é ṣe pé kí àwọn onísègùn náà mọ irú ọgbọ́n yìí. Ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ ẹni tí wọ́n ní ìfẹ́ rẹ̀ ni wọ́n yóò kọ́ ọ nísẹ́ dáadáa kí òun náà ba lè ṣe iṣẹ́ sìn wọ́n díẹ̀ kí ó tó di tara rẹ̀. Ọ̀nà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin yìí ni mo rò pé a lè gbé bí a ṣe ń kọ́ iṣẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá gbà.

Nínú àwọn ọ̀nà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí mo sọ yìí, èyí tó gbòòrò jù ni "àpilẹ̀kọ" nítorí ilé-ẹ̀kọ́ òde- òní ti ya ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ kúrò ní iṣẹ́ bàbá rẹ̀.

## 4.3 Yíya Iṣẹ́

Ní ayé àtijọ́, kò sí àwòkọ́ṣe iṣẹ́ tó bẹ́ẹ̀. Gbogbo iṣẹ́ tí ó ṣe pàtàkì nígbà sáà jẹ́ iṣẹ́ ìdílé tí àwọn ọmọ ń kọ́ bi wọnti ń dàgbà, tí wọn sì ń jogún, bi ewé ti ó gbó ti ewé ń rẹ̀. Iṣẹ́ àgbẹ̀, ọnà-ṣíṣe, ọdẹ ṣíṣe, ìlù lílù, orinkíkọ, epofífọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, kì í ṣe ohun tí ènìyàn le lo bá ẹnikan pé òun fẹ́ kọ́. Ẹni tí a bi sínú ìdílé àgbẹ̀, àgbẹ̀ ni yóò ṣe; ẹni tí a sì bí sí ilé ọlọ́tí pípọn, ọtí ni ọmọ wọn obìnrin yóò máa pọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. síbẹ̀, ojú kò fẹ́ irú rẹ̀ kù pé iṣẹ́ kan wu ènìyàn láti kọ́, ó sì lọ kọ́ irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀, irú àwọn báyìí ni a ń pè ní aláwọ̀ṣe, ojú ọ̀lẹ ni àwọnYorùbá yóò sì máa fi wo irú àwọn bẹ́ẹ̀.

Gẹ́gẹ́ bí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá, tí ọ́mọdé bá tó lọ́kọ́, à á fún un lọ́kọ́ ni, bẹ́ẹ̀ náà ló rí nínú yíya iṣẹ́. Ìtumọ̀ yíya iṣẹ́ tí à ń sọ kì í ṣe kí ọmọ kúrò lábẹ́ òbí rẹ̀ kí ó lọ dá dúró láti máa ṣiṣẹ́ tirẹ̀ lọ́tọ̀, ṣùgbọ́n ọmọ náà yóò ní àǹfààní láti ní gbogbo irin iṣẹ́ tàbí ohun-èlò tí ó jẹ mọ́ iṣẹ́ tí bàbà rẹ̀ ń ṣe, òun pẹ̀lú sì lè máa dá iṣẹ́ gbà, yàtọ̀ sí èyí tí bàbà rẹ̀ bá gbé fún un ṣe. Kò wọ́pọ̀ láyé àtijọ́ kí ọmọ kúrò lábẹ́ òbí rẹ̀ kí ó lọ dá dúró. Iṣẹ́ tí òbí bá ń ṣe ni ọmọ yóó máa ṣe, kò lè dá àsùnwọ̀n ní, bàbá ni yóò máa bọ́ ọ, tí yóò gbéyàwó fún un, tí yóò sì máa bọ́ ìyàwó rẹ̀ pẹ̀lú. Tí bàbá bá sì wá dàgbà tó re ibi àgbà ń rè, ọmọ ni yóó jogún iṣẹ́ náà, tí yóò sì máa ṣe é lọ. Kò sí ọmọ tí ó ń fẹ́ kúrò lọ́dọ̀ òbí rẹ̀, nítorí bí ìgbà tí ọmọ náà hùwà àìtọ́, tí ó fẹ́ gba ìpín ogún tirẹ̀ lójú bàbá rẹ̀ ni yóò rí. Tí a bá wá rí ọmọ tí ó yarí pé òun fé lọ, bàbà rẹ̀ yóò pe gbogbo ẹbí jọ, yóò sì ya iṣẹ́ fún un lójú wọn

## 4.3 Ìpín Kẹta : Iṣé tí àwọn Yorùbá ń ṣe

### 4.3.1 Ìfáárà sí Iṣẹ́ tí àwọn Yorùbá ń ṣe

Iṣẹ́ tí ìran Yorùbá ń ṣe pọ̀ díẹ̀, iṣẹ́ tí ọkùnrin ń ṣe wà, bẹ́ẹ̀ náà sì ni ti obìnrin wà. Gbogbo iṣẹ́ ìran Yorùbá ló níyì, tí wọ́n sì ṣe é mú yangàn. Kò fẹ́rẹ̀ẹ́ sí irú iṣẹ́ tí ó wà ní àwùjọ wa lónìí tí kì í ṣe iṣẹ́ tí a jogún bá lọ́wọ́ àwọn babańlá wa. Ọgbọn àwọn babańlá wa pọ̀ tóbẹ́ẹ̀ tí ó fi jẹ́ pé gbogbo ohun tí wọn nílò ni wọ́n ń ṣe fúnra wọn.

Lára àwọn iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá niwọ̀nyí:

i. Iṣẹ́ Ọdẹ
ii. Iṣẹ́ Àgbẹ̀
iii. Iṣẹ́ Onà ( àgbẹ̀dẹ, igbá fífín abbl)
iv. Iṣẹ́ Ẹbu (epo pupa fífọ̀, ìkòkò mímọ abbl)

### 4.3.2 Àkíyèsí

Tí o bá ṣe àkíyèsí àwọn iṣẹ́ tí a dárúkọ lókè wọ̀yìí, ìwọ yóó rí i pé , iṣẹ́ ọnà àti iṣẹ́ ẹbu ní ọmọ lábẹ díẹ̀. Gbogbo èyí ni a ó tan ìmọ̀lẹ̀ sí ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó wà ní iwájú.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Lábẹ́ Módù Kìíní (ìpín I dé III) ni a ti ṣe àlàyé lórí ohun tí iṣé ṣíṣe jẹ́ láàárín àwọn Yorùbá àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa iṣẹ́, a tẹ̀síwájú láti sọ àwọn àǹfààní tí ó wà nínú ṣíṣe iṣẹ́ àṣekára. Ní Módù Kejì la ti sọ nípa àwọn ọ̀nà tí à

ń gbà láti kọ́ iṣẹ́ àti yíya iṣẹ́. Ní módù Kẹta ni a ti dárúkọ àwọn iṣẹ́ tí Yorùbá ń ṣe ní ayé àtijọ́

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ nípa iṣẹ́
2. sọ àwọn àǹfààní ṣíṣe iṣẹ́ méjì mìíràn tí o mọ̀ yàtọ̀ sí èyí tí a mẹ́nu bà nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí
3. Dárúkọ àwọn iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá márùn-ún

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adéoyè, C.L. 2005. *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Limited

Dáramọ́lá. O àti Jẹ́jẹ.A. 1968. *Àwọn Àṣà Àti Òrìṣa Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press

Ílésanmí, T.M. 1989.*Ìṣẹ̀ǹbáyé*. Ilé-ifẹ̀, University of Ife Press.

Ládélé, T.A.A, et.al. 2006 *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn Gavima Press Ltd.

Ọlájubù, O. 2011. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ìkẹjà, Lagos: Longman Nigeria Plc

# MODÙ KEJI

## 2.1 Ìfáárà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó wà ní Módù kejì yìí, ìwọ yóò kà nípa iṣẹ́ Àgbẹ̀, iṣẹ́ Ọdẹ, àti iṣẹ́ Ọnà. Ní pàtó, ìwọ yóò mọ̀ nípa bí iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ́ ọdẹ àti iṣẹ́ ọnà ṣe rí ni ayé àtijọ́, bákan náà lo máa mọ àǹfààní tí o lè rí nínú àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí, èyí tí ó lè mú kí o ní ìfẹ́ sí àtiyan èyíkéyìí nínú wọn láàyò gẹ́gẹ́ bí i iṣẹ́ òòjọ́ rẹ.

Bákan náà, àwọn ìbéèrè ìṣaájú tí a pèsè sínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò jẹ́ ìrànwọ́ ńlá fún ọ láti fi gbé ara rẹ lé orí oṣuwọ̀n bóyá ohun tí o kà yé ọ tàbí kò yé ọ. Àwọn ìbéèrè sì tún wà fún ọ lẹ́yìn tí o bá ti ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tán fún ìdánrawò láti mọ̀ bí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà ti yé ọ sí. Bí ohun kan bá rú ọ lójú níbẹ̀, ìwọ ṣá tún un gbé, kí o sì kà á ní àkàtúnkà títí tí yóò fi yé ọ dáadáa.

## 2.2 Èròngbà àti Àfojúsùn

Ọ̀nà tí a gbà gbé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí kalẹ̀ jẹ́ èyí tí ó rọrùn. Lẹ́yìn tí o bá ti kà á dáadáa, tí ó sì yé ọ yékéyéké, ìwọ yóò ní ìmọ̀ kíkún nípa nǹkan wọ̀nyí:

- Iṣé Àgbẹ̀
- Iṣẹ́ Ọdẹ
- Iṣẹ́ Ọnà
- Àǹfààní àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí

Gẹ́gẹ́ bí àfojúsùn, ìwọ yóò le ṣennǹkan wọ̀nyí:

- ìwọ yóò lè ṣàlàyé iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ́ ọdẹ àti iṣẹ́ ọnà, ìwúlò àti àǹfààní wọn
- ìwọ yóò ní ìmọ̀ tí ó lè mú ọ yan èyíkéyìí iṣẹ́ náà láàyò.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

- Dárúkọ orísi iṣẹ́ Àgbẹ̀ tí ó wà ní ilẹ̀ Yorùbá.
- Ṣàlàyé ṣókí lórí ohun tí o mọ̀ nípa iṣẹ́ ọdẹ?
- Ṣàlàyé lẹ́kùn-únrẹ́rẹ lórí ẹyọ kan lára iṣẹ́ ọnà
- Èwo nínú àwọn iṣẹ́ yìí ni o lè yàn lááyò?
- Ìdí wo lo fi yan iṣẹ́ náà lááyò.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 ÌpínKìíní: Iṣẹ́ Àgbẹ̀

### 4.1.1 Àlàyé lórí iṣẹ́ àgbẹ̀ àti àǹfààní iṣẹ́ àgbẹ̀

Iṣẹ́ àgbẹ̀ ṣe pàtàkì jùlọ ní ilẹ̀ Yorùbá. Oko ríro ni iṣẹ́ àgbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ ti mọ̀, ká gbin ohun ọ̀gbìn fún jíjẹ àti lílò ni iṣẹ́ àwọn àgbẹ̀, àwọn ni a tún

mọ̀ sí "Olóòògùn ebi". Onírúurú àwọn àgbẹ̀ ló wà, nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a pín iṣẹ́ àwọn àgbẹ̀ sí ọ̀nà márùn-ún. Mo sì fẹ́ kí ẹ mọ̀ tẹ́lẹ̀ pé àwọn ọ̀nà máràárún yìí pín sí ọ̀nà tí ó lé lọ́gọ́rin. Àwọn ọ̀nà márùn-ún ti iṣẹ́ àgbẹ̀ pín sí ni èyí.

i. Àwọn Àgbẹ̀ tí í roko etílé
ii. Àwọn Àgbẹ̀ tí í roko ọgbà
iii. Àwọn Àgbẹ̀ apàjùbà lásán
iv. Àwọn Àgbẹ̀ tí í roko ọgbà
v. Àwọn Àgbẹ̀ tí í roko ẹgàn

**Àwọn àgbẹ̀ Olóko Etílé àti àwọn Olóko Ọgbà:** déédéé ni wọ́n rí ìyàtọ tí ń bẹ láàárin àwọn méjéèjì ni pé olóko etílé máa ń dáko sí ibi tí àwọn ẹran kì í lè e jẹ àwọn ohun tí wọ́n gbìn. Ṣùgbọ́n ẹni tí kò bá lè rìn jìnnà tó bẹ́ẹ̀ tí ó bá sì fẹ́ dáko ní láti ṣe ọgbà yí tirẹ̀ ká, kí ẹnu ẹran má tó ohun tí ó bá gbìn.

**Àwọn àgbẹ̀ Apàjùbà:** kì í ṣe alárotà, aláròjẹ lásán ni wọ́n. Ẹ̀yìnkùnlé ni wọ́n ti ń ṣe ọ̀gbìn kébi má pa wọ́n. Ní kùkúrú àwọn ènìyàn tí à ń pè ní apàjùbà ni awọn alákíkanjú tí wọ́n ṣe àkíyèsí pé ibi tí àwọn kọ́lé sí jẹ́ ilẹ̀ ọlọ́ràá àti pé gbogbo nǹkan tí ó lalẹ̀ hù níbẹ̀ ń sèso rere. Wọ́n á kọ ebè sí ẹ̀yìnkùnlé wọn, wọ́n á sì ṣe aájò ohun ọ̀gbìn síbẹ̀.



**ÀwọnÀgbẹ Àkùrọ:** Inú ẹ̀rùn ni wọ́n ń ṣe ọ̀gbìnní ti wọn,nítorí tí òjò bá ti rọ̀ léraléra,ó máa ń ba ohun ọ̀gbìn wọn jẹ́, nítorí omi yóò ti pọ̀ jù fún ohun ọ̀gbìn náà.

Àwọn ohun ọ̀gbìn wọ̀nyí ni àwọn olóko etílé, olóko ọgbà àti apàjùbà sábáà máa ń gbìn, Ọkà, àgbàdo, ọkà bàbà, igbá àdému, igbá pàlátà,àdóòjọ̀lọ̀, àdó atọ́, ṣẹ́ẹ́rẹ́, agbè, bàárà, elégédé, ẹ̀wà erèé, ẹ̀wàeèré,

òtílí awúję, gbọ̀rọ̀, ẹ̀gúsí ìtóò, ẹ̀gúsí ẹpẹ̀ẹ́, ẹ̀pà yẹsa, ẹ̀pà roro, ẹ̀mú, iṣu èsúrú pupa, èsúrú funfun, akọsu, ewùrà, ẹ̀gẹ́ ẹran, kókò, ọ̀dùnkún ẹ̀gẹ́ tútù tí wọ́n fi ń gúnyán jẹ, ata wẹẹrẹ, atarogodo, àlùbọ́sà eléwé, àlùbọ́sà rogodo, àwọn nǹkan tí wọ́n kó wọ̀lú bí i, tìmáátì rogodo, tìmáátì gbọọrọ, ẹ̀fọ́ ìgbó, ọ̀sàn, ebóló tàbí sọkọyọ̀kọ̀tọ, tí wọ́n ń pè ní sọmọsọ́la, tẹ̀tẹ̀ àbáláyé, tẹ̀tẹ̀ òpòpó,ṣawere, gbúre, yánrin òdú, ewúro odò, àjefọ́wo, akúmalapa, gbọlọgi, ṣẹ̀jẹ̀ṣòro, ewébẹ̀ bí ewédú tàbi ọ́óyọ́, ìlasa, ohun ọbẹ̀ bíi ilá-yílá, ilá ìròkò, àwọn èso bíi iṣin, àti bíi òrombó to lómi àti wẹ́wẹ́ tí wọ́n fi ń ṣe egbò igi, èso òyìnbó tí wọ́n ń pè ní mọ́ńgòrò, òro tí à ń fi èso rẹ̀ ṣe àpọ́n àwọn ohun elò bíi atalẹ̀ àti atare.

Lẹ́yìn àwọn nǹkan ti a dárúkọ yìí, àwọn nnkan mìíràn tún wà jáǹtìrẹrẹ tí àwọn àgbẹ̀ kéékèèké tí a sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí le ṣe ọ̀gbìn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ; kì í ṣe èèwọ̀ fún wọn láti ṣe ọ̀gbìn àwọn nǹkan bí ìbẹ́pẹ tàbí ọsàn.

**Àwọn Àgbẹ̀ olóko Ẹgàn:** ni wọ́n máa ń ṣe ọ̀gbìn sí àárin igbó tàbí aginjù. Àárín igbó àti ijù yìí náà ni ibùdó àwọn ẹranko ńláńlá, àwọn àgbẹ̀ yìí ní ọgbọ́n tí àwọn ẹranko kò fi lè jẹ ohun ọ̀gbìn wọn. Irú ọgbọ́n bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń pè ní "**Aṣọ́kopẹ́**" àti "**Aṣọ́komásùn**". Aṣọ́kopẹ́ ni igi kúkúrú ti ó ga tó ènìyàn tí kò sì sanra púpọ̀ tí wọ́n máa ń wọ̀ láṣọ bí ènìyàn tó jẹ́ pé nígbà tí àwọn ẹranko ńlá bá rí i,wọn á rò pé olóko ni. Nípa bẹ́ẹ̀ wọn kò ní tètè wọnú oko láti ba àwọn èrè oko jẹ. Àwọn 'asọ́komásùn' ni àwọn ìkarahun ìgbín tí wọ́n dìjọ tí wọ́n sì ń so mọ́ ara igi lóko, nígbà tí afẹ́fẹ́ bá fẹ́ yẹ́ẹ́ tí àwọn ìkarahun wọ̀nyí bá fi ẹ̀gbẹ́ gbún ara wọn, gbogbo ẹranko á sálọ, èrò wọn ni pé ohun ewu ni ó ń bọ̀ wá bá wọn.

Díẹ̀ nínú ohun ọ̀gbìn tí àwọn àgbẹ̀ ẹgàn máa ń gbìn ni ìwọ̀nyí: kòkó, obì àbàtà, obì gbàǹja, orógbó, ọkà bàbà tí ó pọ̀, àgbàdo, ẹ̀wà erèé lọ́pọ̀lọpọ̀, ẹ̀wà ẹwẹ bẹ́ẹ̀ òtíílí, awúję, koto, àdóyádòó, àdójọọ̀lọ̀, atọ́, ṣẹ́ẹ́rẹ́, elégédé, bààrà, ọ̀pẹ ńlá, ọ̀pẹ òyìnbó oníṣágo, àgbọn gidi, àgbọn olódu, ẹ̀gúsí ìtóò, ẹ̀gúsí ẹpẹ̀ẹ́, ọ̀pẹ̀kẹ́tẹ̀, ọ̀pẹ òyìnbó adunlẹ̀rùn, ìyeré, akọṣu, ewùra, kókò, ewùra pupa, èsúrú funfun èsúrú pupa, ọ̀dùnkún, pákí ati oríṣìiríṣìí ata.

Ní ayé òde-òní púpọ̀ ni àwọn akíkanjú akẹ́kọ̀ọ́gboyè lọ́kùnrin àti lóbìnrin ti wọ́n yan iṣẹ́ àgbẹ̀ lááyò, pààpàá jùlọ, àgbẹ̀ àkùrọ̀ àti apàjùbà. Wọ́n máa gbin àwọn nnkan tí ó wúlò àti oríṣìiríṣìí nǹkan ọ̀gbìn tí kò wa oko ríro ní àrodùnra. Nígbà tí àwọn alákọ̀wé tí púpọ̀ nínú wọn rí jẹ tí wọ́n sì rí mú sẹ́kù, ń gba irú ìyànjú báyìí, kò sí ẹni tí ó pọ̀ jù fún láti ṣe iṣẹ́ àgbẹ̀. Àwọn àgbẹ̀ jẹ́ kòṣémánìí ní ibi gbogbo, àwọn ni kò jẹ́ kí ebi pa ìlú. Ó yẹ kí gbogbo wa múra sí iṣẹ́ àgbẹ̀ pàápàá lákòókó tí a wà yìí tí oúnjẹ di góòlù.

Kí á tó dánu dúró lórí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó yẹ kí á sọ méjì tàbí meta lára àǹfààní iṣẹ́ àgbẹ̀:

1) Ìpèsè oúnjẹ lọ́pọ̀ yanturu fún aráàlú

2) Ìpèsè iṣẹ́ fún àwọn tó ń wáṣẹ́, tí wọ́n sì pinnu láti ṣe iṣẹ́ àgbẹ̀
3) Ọ̀nà okòwò fún àwọn tí ó ń ta irè oko
4) Mímú kí ètò ọrọ̀ ajé oríléèdè rú gọ́gọ́

## 4.2 Ìpín Kejì: Iṣẹ́ Ọdẹ

## 4.3 Àlàyé lórí iṣẹ́ ọdẹ àti àǹfààní iṣẹ́ Ọdẹ

Oríṣì iṣẹ́ ọdẹ méjì péré ni ó wà. Èkíní ni ọdẹ òkè tí a tún mọ̀ sí ọdẹ orí ilẹ̀, èkejì sì ni ọdẹ odò tí a tún ń pè ní ọdẹ omi.

Àwọn ọdẹ orí ilẹ̀ (ọdẹ òkè): Ọdẹ aperin ni àkọ́kọ́, àwọn ni ọdẹ tí ó máa ń pa àwọn ẹranko abìjà bí i, ẹfọ̀n, ẹkùn, kìnìún tí ó jẹ́ ọba gbogbo ẹranko.

Àwọn ọdẹ Agẹ̀gùn: ni ìkejì,àwọn agẹ̀gùn yìí lè jẹ́ tafàtafà tàbí agbébọnléká.

Àwọn ọdẹ tí ń wọ oko: ló tẹ̀lé agègùn, ọdẹ tí ń wọ oko kan náà yìí ni àń pè ní ọdẹ adẹjá.

Ọdẹ Asun pápá: ni ìkẹrin, àwọn ló máa lo òlùgbóńdóró, kùmọ̀, sẹ́rin, àdá, àti ìbọn pẹ̀lú ọfa.

Àwọn ọdẹ tí ń gbẹ́hò, tàbí àwọn tí ń fi iná fín ihò ni ìkarùn-ún
Àwọn tó ń lo Àtè: ni oríṣì kẹfà, ẹyẹ ni wón ń lo àtè fún.

Àwọn to ń lo ẹ̀bìtì, pàkúté: ni ó wà ní ipò keje nínú onírúurú ọdẹ ṣíṣe.
Yàtọ̀ sí àwọn tí a ti mẹ́nu bà, a tún ní Ọdẹ adẹ̀rin,àwọn tí í dẹ ìkọ̀ǹkọ̀sọ̀,àwọn ọdẹ tí ń dẹ àpẹ̀rẹ̀ tàbí agbọ̀n àti àwọn mìíràn.

Díẹ̀ lára àǹfààní iṣẹ́ ọdẹ ni:

1. Kíkọ́ ni bí a ṣe ń ní ìgboyà
2. pípèsè ẹran fún jíjẹ àti títà
3. Ìpèsè iṣẹ́ oúnjẹ òòjọ́



**4.3.1 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Iṣẹ́ Ọdẹ**

1. Ọta : Oríṣirííṣi ẹ̀yà òkò tí a fi ń ki ìbọn
2. Ògún yóò kó àkódọ́wọ : Ó túmọ̀ sí pé ọdẹ kò níí rìn jìnnà kó tó rí ẹran pa
3. Òribi : Irúfẹ́ òkò kan tí a fi ń ki ìbọn ó dúdú, ara rẹ̀ ń dán, ó sid rí bíi kóró ọkà bàbà
4. Rúgbẹ̀ẹ́ : Kí á lo ènìyàn tàbí ajá ọdẹ láti máa lé ẹranko sí ọdẹ ní àsìkò tí à ń dẹ ìgbẹ́ ọdẹ
5. Gbérí-ọdẹ : Ẹ̀wù tí àwọn ọdẹ máa ń wọ̀ lọ sí oko ọdẹ, ó rí bíi àlàbọrùn
6. Gẹ̀gùn : Kí ọdẹ gọ tàbí fi ara pamọ́ sí orí igi tàbí ibi igbó ṣúúrú kan, láti dúró de ẹran tó fẹ́ pa
7. Gánnà : Ọ̀nà ilàgbẹ́ tí àwọn ọdẹ máa ń lò láti fi ṣọdẹ nínú igbó

## 4.3 Ìpín Kẹta: Iṣẹ́ Ọnà

### 4.3.1 Àlàyé lórí iṣẹ́ ọnà

**Iṣẹ́ ọnà**

Iṣẹ́ ọnà gbòòrò púpọ ní ilẹ̀ Yorùbá láti ìbẹ̀rẹ̀ wá, kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú àwọn iṣẹ́ ọnà olókìkí orílẹ̀-èdè gbogbo ní ilẹ̀ ayé yìí. Gẹ́gẹ́ bí moti sọ ṣáájú, ẹ̀ka tí iṣẹ́ọnà pínsí po, ṣùgbọ́n a ó mẹ́nubadíẹ̀tí ó ṣepàtàkì jù.

Araiṣẹ́ ọnà yorùbá ni: àgbẹ̀dẹ ṣíṣe, igigbígbẹ́, igbá fífín, orinkíkọ, ìlù lílù, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. pàtàkì jùlọ niàgbẹ̀dẹ ṣíṣe jẹ́ nínú iṣẹ́ ọnà wa, èyí ni ‘Àgbẹ̀dẹ Ògún’ nítorí pé bí kò bá sí alágbẹ̀dẹ kò lè sí ọkọ́, kò lè sí ọ̀bẹ ìkọlà, kò lè sí ọ̀bẹ ìfíngbá, kò lè sí ọta ìbọn, kò lè sí tàkúté àti irú nǹkan bẹ́ẹ̀ gbogbo tí wọ́n ń rọ ní àgbẹ̀dẹ.


Iṣẹ́ ọnà ṣe pàtàkì, Ògún lákáayé ni ìtàn sọ fún wa pé ó dá a sílẹ̀. èyí náà ni ó fa àwọn gbólóhùn díẹ̀ yìí:

> 'Òrìṣà tí yóó ṣe bí Ògún kò sí mọ́
> Bí kò sí Onírè a kò roko
> Bi kò sí Onírè a kò yẹ̀nà,
> Bí kò sí Onírè a kò ti ẹrú gódógbó ṣaájú.

Nítòótọ́ iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé ni àgbẹ̀dẹ ṣíṣe jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá tí ó sì jẹ́ pé a fi ń rọ ọkọ́, àti àdá, a fi ń rọ ọ̀bẹ àti ọ̀pọ̀ nǹkan mìíràn kí àwọn aláwo funfun tóó dé ọ̀dọ̀ wa síbẹ̀, iṣẹ́ náà kò kẹ̀rẹ̀ di òní olónìí yìí bẹ́ẹ̀ ni àwọn tí ó ń ṣe é kò ṣàìmáarí ṣe ju ti ìgbà àtijọ́ lọ.

**Iṣẹ́ ọnà àwọ**: ni a ti rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ tí ó jẹ́ iṣẹ́ ìran àwọn Ẹfọ̀n, Ògbùró, Àágberí àti àwọn mìíràn. Ọnà awọ ni a fi ń ṣe apò ìfàlówọ́, tìmùtìmù, apó, àkọ̀, bàtà aláwọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Iṣẹ́ igbá fífín**: àwọn ìran Ìrèsé ni ó ń fín igbá. Onírèsé ni ẹni tó máa ń fín igbá fún ọba Aláàfin nígbà tí ayé rójú kí ọba tóó fi jọba sí ìgbèríko. Èyí ló bí òwe tí wọ́n máa ń pa pé bí Onírèsé kò fíngbá mọ́, èyí tó fi fín kò le è parun.



**Ọnà Igi**; èyí ni igi gbígbẹ́. Abógundé tí wọ́n ń ki orílẹ̀ẹ rẹ̀ ni: Àrè Ọ̀jẹ̀ Ọlọ́jọwọ̀n' ni ìran rẹ̀ máa ń gbẹ́gi fún ọba Aláàfin. Abógundé jẹ́ jagunjagun Aláàfin Ọ̀yọ́, nítorí kí o máa baà ṣe jìnnà sí, ó fún un ní ilẹ̀ láti tẹ̀dó sí ó sì sọ ibẹ̀ ní Abógundé. Ìran Abógundé ló máa ń gbẹ́gi fún Ọba àti ilé ọba. Òun ni ìtàn sọ fún wa pé ó jẹ́ agbẹ́gi àkọ́kọ́ ní ilẹ̀

Yorùbá. Àwọn ni wọ́n ń gbẹ́ ọpọ́n ìjẹun, àpótí ìjókòó fún ọba, ìjòyè àti mẹ̀kúnnù. Àwọn ni ó ń gbẹ́ ère ènìyàn àti ohun gbogbo tí ó bá jẹ mọ́ ọnà igi. Àwọn òpìtàn tilẹ̀ sọ pé ní ọjọ́ kan tí Ìyá Aláàfin kan sọnù, Abógundé ni Ọba pàṣẹ fún láti gbé ère rẹ̀ sí ààfin kí gbogbo ọba ìgbèríko máa wò ó bí wọn yóò bá rí i lódọ̀ọ wọn kí wọ́n lè dá a mọ̀. Abógundé yìí ti ipa iṣẹ́ ọnà ńlá yìí di olókìkí jákè jádò ilẹ̀ Yorùbá.Ọ̀pọ̀ ère ìsẹ̀ǹbáyé tí àwọn aláwo funfun wa ń jí kó lọ ní ilẹ̀ Yorùbá jẹ́ iṣẹ́ Abógundé, tí ìran tàbí tí ìmọ̀ iṣẹ́ rẹ̀. Nígbà ogun Ọ̀yọ́ ilé ni ogun tú Abógundé pẹ̀lú, àwọn ìran rẹ̀ sì sa wá sí ìlú Ògbómọ̀ṣọ́, níbi tí ìran wọn wà di òní yìí.



Púpọ̀ ènìyàn ni ó ṣe iṣẹ́ ọnà yíí lónìí, wọn ń gbẹ́ ère lóríṣiríìṣi, wọn ń ya àwòrán, wọn ń fín igbá ,fún títà fún ẹni tó bá nífẹ̀ẹ́ sí i, tí wọn sì tún ń kó wọn lọ sí Òkè-okun fún títà. Ní àwùjọ wa lónìí, àwọn ènìyàn má ń fi àwọn iṣẹ́ ọnà yìí ṣe ẹ̀bùn fún àwọn tí ó bá ṣe ayẹyẹ ọjọ́ ìbí, ìgbéyàwó, oyè jíjẹ àti àwọn ayẹyẹ mìíràn. Tí a bá si dé ilé ọ̀pọ̀ ènìyàn pàápàá àwọn ọlọ́lá ní àwùjọ, a ó rí i tí wọ́n fi àwọn iṣẹ́ ọnà yìí ṣe ọ̀ṣọ́ sí ilé wọn.

**Iṣẹ́ Gbẹ́nàgbẹ́nà:** Ní ayé àtijọ́, iṣẹ́ àwọn ọ̀kùnrin ni iṣẹ́ gbẹ́nàgbẹ́nà ní ilẹ̀ Yorùbá. Iṣẹ́ pàtàkì sì ni bí a bá dé àfin àwọn Ọba, ilé àwọn olóyè sàràkí sàràkí láwùjọ, tàbí ilé àwọn òtọ̀kùlú ìlú, dandan ni kí a rí ọwọ́ àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà bí wọ́n ti máa ń fi igi dá oríṣiríṣi àrà. Bí wọ́n ti ń gbẹ́ igi tí a fi ṣe òpó ilé Ọba, ni wọ́n ń gbẹ́ igi tí a fi ṣe ilẹ̀kùn tí ó jáde sí gbàgede Ààfin. Àwọn gbẹ́nànẹ́nà ló máa ń gbẹ́ oríṣiríṣi ère tí àwọn ọlọ́lá fi ń dárà sí ilé wọn. Àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà lè gbẹ́ ère àkùkọ, ẹkùn, ológbò

tàbí ẹyẹ. Wọ́n tílẹ̀ lè gbẹ́ àwòrán ènìyàn tí yóò sì dábì ẹni náà lójú ayé. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọ́n ará ìlú ló sì máa ń ra àwọn íṣẹ́ ọnà yìí láti ṣe àtúntà tàbí láti tọrẹ fún àléjò.

Ilé àwọn Ọba tàbí ọlọ́lá nìkan kọ́ la ti máa ń rí iṣẹ́ ọwọ́ àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà. Tí a bá ṣe àbẹ̀wọ sí àwọn ilé iṣẹ́ ìsẹ̀nbáyé, a ó rí oríṣiríṣi àra tí àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà ti fi ọwọ́ dá. Ní àwọn ilé-ìsẹ̀nbáyé tí a ń sọ yìí, a óò rí ère àwọn ènìyàn ńlánlá tó ti gbélé ayé ṣe rere ní ilẹ̀ Yorùbá. Bákan náà ni a o rí àwọn ohun èlò ìsẹ̀nbáyé bí adé ọba, ọ̀pá ìtìlẹ̀ ọba, àga ọba, ère àwọn òrìṣà ìbílẹ̀ Yorùbá àti adé àwọn ohun mèremère mîìràn. Kìí ṣe igi nìkan ni àwọn gẹ́nàgbẹ́nà lè fi dárà, wọ́n máa ń fi irin, fàdákà tàbí òkúta náà dárà.

Iṣẹ́ tó lérè lórí púpọ̀ ni iṣẹ́ yìí, kódà wọ́n máa ń kó àwọn iṣẹ́ wọn lọ sí òkè-òkun lórí èyí tí wọ́n máa ń rí owó tabua. Lara awon onise gbenagbena aye ode oni la ti ri Alagba kan ti a mo si Ṣẹ̀san Ajéwọlé ni ìlú Ibadan ati Daniel Alagba ni ilu Ìlọ́rọ̀-Ekiti. A ri awon akekoo to n gboye imo ijinle ninu ise gbenagbena ni awon Yunifasiti wa ati ile-eko gbogbònṣe.

Awon Ohun Elo Ise Gbenagbena

Awon ohun elo ise gbenagbena laye atijo ni aake, ada, obe, osese, sugbon laye ode oni, ìmọ̀ ẹ̀rọ ti je ki ise gbenagbena di irorun. Orisirisi ni awon ero igbalode ti awon gbenagbena maa n lo lati re igi, fa igi, dan igi ati lati da orisirisi ara to ba wu won si ara igi, okuta tabi irin. O se Pataki ki a salaye pe ninu awon ohun ti gbenagbena le lo lati fi dara, igi lo gbajugbaja ju. Idi ni pe ko nira pupo bi awon eyi to ku, o si maa n gbe ewa ise won yo rekete. Iru ise ona ti gbenagbena ba fe gbe ni yoo so iru igi ti yoo lo. Bi apeere, igi omo la fi i gbe odo. Ti o ba si je awon ise ona bi ere ti a fi n se ile losoo, igi to le koko bi iroko tabi oganwo ni won maa n lo.

**Apeere Awon Ise Ọnà ati bi a se le Gbẹ́ won**

**ODÓ**

Igi ọ̀mọ̀ ni a fi maa n gbe odo. Igi naa gbodo tobi gan an ni. Idi ni pe bi igi ba ṣe tóbi tó naa ni odó yóò tóbi tó. Bi a ba ti ge igi balẹ̀ tán, a o tun la ìké igi kọ̀ọ̀kan si ìwọ̀n tí a fẹ́ ḱi odó mọ. Lẹ́yin naa, a o fi ọ̀sẹsẹ gbẹ́ ihò sínú ìké igi naa (Iho naa le to aabo ese bata kan). A o fi ọ̀sẹsẹ kekere fẹ ihò naa seyìn ninu ike igi. Leyin eyi ni a o maa gbe ayika ara odo. Nigba ti a ba n gbe ara odo naa ni a o se itise tabi itele re ki o ma baa maa yi gbirigbiri lori ile.

**ỌMỌ ODÓ**

Igi tẹ́ẹ́rẹ́ la fii gbẹ́ ọmọ odó, ṣugbọ́n igi naa gbodo jé eyi tó le koko. Apeere igi to le koko ti a saba maa n lo ni ‘akika’.

## ÈRE GBÍGBẸ́

Bi a ba fe gbe ere, o di dandan ki a ni àwòrán rẹ̀. Eyi ni yoo ran gbenagbena lowo lati le se ise ona ti yoo jo eni tabi ohun naa ni àjọtán. Bi o tile je pe awon gbenagbena kan wà tó ní ẹ̀bun àtinúdá débi pé wọ́n lè gbẹ́ ère láìwo aworan Kankan, lílo àwòrán yóò jẹ́ kí ó rọrùn fun gbẹ́nàgbẹ́nà nitori pe amúṣẹ́yá ni eyi jẹ́ fun un. Orí ni gbenagbena kọ́kọ́ maa n yọ lara igi tabi okuta, paapaa to ba je ere ti yoo ni ori, ese tabi awon eya ara miiran. Lára orí yìí ni gbẹ́nàgbẹ́nà yóò ti yọ ọrùn, ojú, imú, etí àti ètè. Lẹ́yìn eyi ni a ó tó fi ọ̀sẹ̀sẹ̀ àti ọ̀bẹ yọ àwọn ẹ̀yà ara yòókù. Ìbáà jẹ́ ènìyàn tabi eranko ni a fẹ́ gbẹ́, ìgbésẹ̀ kan náà ni. Iṣẹ́ èrè gbígbẹ́ gba ìfarabalẹ̀, ìmọ̀-ọ́n-ṣe àti suuru to ga. Leyin ti a ba gbe ere tan ni a fi àwọ̀ to dara se e lọ́sọ̀ọ́. Ni aye atijo, awon gbenagbena a maa lo ẹfun tabi osùn lati kun ere. Eyi túmọ̀ sí pe enikeni to ba kọ́ ise gbenagbena maa n kọ́ iṣẹ́ ọ̀dà kíkùn mọ́ ọn ni. Idi ni pe eni to gbẹ́ ere naa ni yoo mo iru awo ti yoo gbe ewa ere naa jade.

Ni aye ode oni, imọ̀ ẹ̀rọ igbalode ti je ki oda orisirisi pọ̀ jaburata. Eyikeyii to ba wu onise gbenagbena ni yoo lo. Awa naa lè lo ọgbọ́n ibile lati se oda gege bi awon Oyinbo ti n se tiwon. Bi apeere, ni aye atijo, bi awon babanla wa ba fẹ́ se ọ̀dà funfun, won yoo mu ìkarahun ìgbín. Won a fi ara rẹ̀ ra iná fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́. Nigba ti ina ba bu ikarahun igbin naa, won yoo yọ ọ́ jade ninu ina, won á lọ̀ ọ́ lúbúlúbú. Lẹ́yìn naa won yoo fi omi tó mọ́ gaara pò ó. Ko si ohun ti a fi oda yii kun ti ko ni funfun bi egbon owu. Ni ti oda pupa, osùn tabi àwọn okuta pupa ni a maa n lo. Leyin ti a ba ti lọ òkúta pupa kúnna lubulubu, a o fi omi pò ó. Ki awon gbenagbena to kun èrè ni oda, won maa n fi oje igi ahun kun ara rẹ. Won n se eyi ki ọ̀dà naa le pẹ́ ki ó tó ṣá ni.

### 4.3. 1.1 Díẹ̀ Lára Ẹ̀dè Àmúlò Iṣẹ́ Ọnà

1. Pafà : Igi tàbí pákó pẹlẹbẹ tí Oníṣọ̀nà ń gé awọ lórí rẹ̀
2. Ọ̀já : Awọ tí a fi ń gbá awọ méjì papọ̀
3. Osán : Awọ tẹ́ẹ́rẹ́ tí Oníṣọ̀nà fi ń rán nǹkan papọ̀
4. Ìrù : Awọ tó ní yẹtuyẹtu ní etí tí a rán mọ́ tìmùtìmù yípo
5 Ìlu-Ọnà : Irin tẹẹrẹ tó mú tí a fi ń lu awọ
6 Tàgíiri : Èso igi pẹlẹbẹ tí a fi ń tu irun ara awọ ẹran dànù
7. Àókó o: Ọnà tí à ń gbà kí gbẹ́nàgbẹ́nà
8. Ààké boro : Ààké kékeré tí à ń fi ọwọ́ kan dì mú láti lò
9. Ṣísù : Irin tó gùn gbọọrọ díẹ̀ tí a fi ń ṣe ọnà awọ
10. Ọ̀bẹ Ifá : Ọ̀bẹ tí ó tẹ̀ kọdọrọ bí iwọ̀, a fi ń ha inú igbá kí ó lè mọ́

### 5.0 Ìsọniṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí a ti ṣàlàyé iṣẹ́ àgbẹ̀, àǹfààní iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ́ Ọdẹ àti àǹfààní rẹ̀. A kò ṣàìjíròrò lórí iṣẹ́ ọnà àti ìwúlò rẹ̀ ní àwùjọ.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

Gbìyànjú láti dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí:

1. Ṣàlàyé ohun tí o mọ̀ nípa Àgbẹ̀ olóko ẹgàn
2. Ìyàtọ̀ wo ló wà láàárín Aṣọ́komásùn àti Aṣọ́kopẹ́?
3. Dárúkọ oríṣi Ọdẹ márùn-ún àti iṣẹ́ wọn
4. Ǹjẹ́ iṣẹ́ Ọnà ṣì tún wúlò láyé òde-òní. Ṣàlàyé?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasi

Adéoyè, C.L. 2005. *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Limited

Dáramọ́lá. O àti Jẹ́jẹ.A. 1968. *Àwọn Àṣà Àti Òrìṣa Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press

Ílésanmí, T.M. 1989.*Ìṣẹ̀nbáyé*. Ilé-ifẹ̀, University of Ife Press.

Ládélé, T.A.A, et.al. 2006 *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn Gavima Press Ltd.

Ọlájubù, O. 2011. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ìkẹjà, Lagos: Longman Nigeria Plc

# MÓDÙ KẸTA: ÀWỌN IṢẸ́ ÌṢẸ̀ǸBÁYÉ ILẸ̀ YORÙBÁ APÁ KEJÌ

## 1.0 Ìfáárà

Ní Módù Kẹta yìí, ìwọ yóò kà nípa àwọn iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá tí a mọ̀ si iṣẹ́ Ẹbu. Èyí ni àwọn iṣẹ́ bí i, epo pupa fífọ̀, Àdí ṣíṣe, Aró dídá, Ọtí pípọn, àti Ìkòkò mímọ. Gbogbo èyí ni ìwọ yóò ní òye rẹ̀ ni Módù Kẹta yìí.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà módù yìí niláti jẹ́ kí o mọ̀ nípa iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé wọ̀nyí, kí o lè gbìyànjú láti yan èyí tí o bá fẹ́ nínú wọn lááyò. Gẹ́gẹ́ bí àfojúsùn, ìmọ̀ tí o ní nípa àwọn nǹkan tí a mẹ́nu bà lókè yìí yóò jẹ́ kí o lè ṣe nǹkan wọ̀nyí:

(i) Ìwọ yóò lè ṣàlàyé nípa àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́.
(ii) Ìwọ yóò lè ṣàlàyé kíkúnlórí bí a ṣe ń ṣe àwọn iṣẹ́ náà.
(iii) Ìwọ yóò lè yan èyí tí o bá fẹ́ lááyò

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

(i) Dárúkọ àwọn iṣẹ́ Ẹbu
(ii) Ṣàlàyé bí a ṣe ń ṣe epo pupa
(iii) Kín ni lábúlábú?
(iv) Sàlàyé bí a ṣe ń ṣe irú
(v) Bawo ni a ṣe ń sun ìkòkò?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìpín Kìíní : Iṣẹ́ Ẹbu

#### 4.1.1. Epo Pupa Fífọ̀

Nínú gbogbo igi tó wà nínú igbó, kò sí èyí tí ó ń so owó to igi ọ̀pẹ nítorí pé kò sí ohunkóhun tó wà lára igi ọ̀pẹ tí í kì í fa owó wọlé. Ọ̀kan nínú ohun tí a ń rí lára ọ̀pẹ ni epo pupa.

Tí a bá fẹ́ ṣe epo, a o kọ́ ààké-ìkọ̀pẹ, àdá àti igbà; a o gbọ̀na ìdí ọ̀pẹ tí ẹyìn (èso) rẹ̀ ti pọ́n lọ. àdá ni a o fi ju ọ̀nà lọ sí ìdí ọ̀pẹ, a ó sì tún ju ìdí ọ̀pẹ náà mọ́ dáadáa kí a le rí ẹyìn tí ó bá rẹ̀ dà sílẹ̀ sà dáadáa. A ó di igbá mọ́ ara ọ̀pẹ, a ó máa sùn tọ igbá bí a ti ń sún un mọ́ òkè.

Orísìí igbà méjì ni a máa ń lò – ọ̀pàkà àti ọkẹrẹ. Ọ̀pàkà ya ju ọkẹrẹ lọ ṣùgbọ́n ọkẹrẹ a máa dín jíja lórí ọ̀pẹ kù. A ó kọ àwọn odi-ẹyìn ọ̀pẹ tí ó pọ́n lórí igi ọ̀pẹ yìí, ó le jẹ́ ọ̀kan, méjì tàbí mẹ́ta, a ó sọ̀kalẹ̀ láti lọ kọ àwọn ọ̀pẹ ìyókù tí odi-ẹyìn wọn bá pọ́n. Bí a ti ń kúrò ní ìdí ọ̀pẹ kan ni àwọn tí yóò máa gbe odi-ẹyìn ọ̀pẹ lọ sí ahéré yóò máa rù ù lọ, wọn yóò

sì máa ṣa ẹ̀rẹ̀-ẹyìn, èyí ni ẹyìn ọ̀pẹ t'ó ti rà lát'orí ìyá rẹ̀. Wọ́n yóò máa ko odi-ẹyìn jọ sí ibìkan, ẹrẹ-ẹyìn sí ibòmíràn. Lẹ́yìn tí a bá ti kọ ọ̀pẹ tán, a o fi àáké ṣá ẹyìn kúrò lára ṣàngílìti,( ígbùndúku tí ṣọṣọ-ẹyìn so mọ́), a ó kó gbogbo ẹyìn tó wà lára ṣọṣọ jọ, (ọ̀pá ti ẹyìn ọ̀pẹ so mọ́); a ó wa fi imọ̀ ọ̀pe bò ó dáadáa.

Tí ó ba di ọjọ́ kejì sí ọjọ́ kẹta, ẹyìn yóò ti rọ̀ dáadáa, a ó wa máa yọ ẹyìn kúrò nínú ṣọṣọ, a ó máa dà á sínú ìkòkò kan. A ó dá iná síìdí ìkòkò ní áàrin ìta, a ó bu omi sí inú rẹ̀, yóò mu ẹyìn dáadáa. Bí omi bá ti ń gbẹ lórí ẹyìn ni a ó máa bu omi mìíràn lé e. tí ẹyìn bá ti rọ̀, a kò níí koná mọ́ ọn mọ́, a ó fi i sílẹ̀ nínú ìkòkò di ọjọ́ kejì. Ẹ̀wẹ̀, ní ọjọ́ kejì, a ó pọn omi sínú ìkòkò mìíràn, a ó máa bu ẹyìn tí a ti ṣe sínú odó, a ó fọ ẹsẹ̀ nù, a ó wá kó ẹsẹ̀ méjéèjì sínú odó, a ó máa tẹ ẹyìn yìí síhìn-ín-sọ́hùn-ún. Bí a ti ń ṣe èyí ni iṣu ẹyìn yóò máa ṣí kúrò lára èkùrọ́. Tí a bá rí i pé ara èkùrọ́ mọ́ dáadáa, tí kò sí iṣu lára rẹ̀ mọ́, a ó da omi inú odó sínú ìkòkò mìíràn, a ó bu omi sí ti yoò pọ̀ daadáa, a ó máa fi ọwọ́ rò ó pọ̀ lògbòlògbò. Nípa ṣíṣe báyìí ni a ń sọ pé a ń pòṣùùrù epo. A ó wá máa ré epo tí ó léfòó sí inú ìkòkò mìíràn. Báyìí ni a ó máa fi ọwọ́ rú omi yìí pọ̀ títí tí epo yóò fi léfòó tán, tí yóò wa ku ihá àti èkùrọ́ ní ìsàlẹ̀. Bí a ti ń rú omi yìí pọ̀, ni a ó máa yọ ihá tí epo kò bá sí lára rẹ̀ mọ́ sílẹ̀, a ó sì máa ré epo tí óléfòó sínú ìkòkò. Tí a bá yọ epo tán, a ó wa èkùrọ́ sá síta.



Lẹ́yin tí a bá ti yọ epo yóò máa hò pùtùpùtù. Báyìí ni a ó máa ko iná mọ́ ọn títí tí omi ara epo yóò fi gbẹ tán, tí yóò wa ku epo nìkan. Tí a bá fẹ́ mọ̀ bí omi tán lára epo bí kò tán, a ó kan omi tútù díẹ̀ sí epo tí ó wà lórí iná; a kò níí gbọ́ ariwo kankan. Tí a bá rí i pé omi tán lára epo yìí, a ó dẹ́kun iná kíkò títí tí epo yóò fi tutù. Tí epo bá tutù, a o rọ ọ́ sínú rùbà, (agbè bí àgé tí à ń rọ epo sí nínú), agbè ńlá tàbí garawa. Ní ìsàlẹ̀ epo inú ìkòkò, a ó rí èyí tí ó ki lẹ̀kẹ̀tì, tí à ń pè ní ìkẹ̀tẹ̀. Èyí ni a máa fi ń jẹ iṣu, a sì tún n fi í ṣe ọbẹ̀. Bí a ṣe ń ṣe epo olóòórùn tàbí epo ìsèlé ni a ti wi yìí. Ọ̀tọ̀ ni bí a ṣe ń ṣe epo Ìbọ̀lọ́ tí à ń pè ni bọ́lugi

### 4.1.1.1 Àkíyèsí

Okè-ògùn ni apá ìwọ-oòrùn Ọ̀yọ́ ni epo ìsèlé wà, ṣùgbọ́n ìbọ̀lọ́ ni epo àwọn Ègbá, Ìjẹ̀bú, Oǹdó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínu ẹkù, èyí ni kòtò tí a gbẹ́, ibẹ̀ ni àwọn tí ń fọ epo tíwọn dípò inú odò. Wọ́n kì í se epo tiwọn jinná dé ibi ki omi tan lára epo tí wọn fi máa yẹ iná kúrò nídìí rẹ̀, ìyàtọ̀ tí ó wà nípa irúfẹ́ epo méjéèjì yìí kò jù báyìí lọ. Ihá tí a rí yọ, èkùrọ́ tí a rí yọ, di sísá. Tí ìhà ba gbẹ, a ó máa fi dáná. Èyí ti epo bá kù lára rẹ̀ ni à ń pè ni ògùṣọ̀ ti a fi ń dáná bákan náà. tí èkùrọ́ bá gbẹ, a ó pa á láti fi ṣe àdí tàbí yánkò.

### 4.1.1.2 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Epo Fífọ̀

1. Ihá : ki ni ti o rí bí i kàn-ìnkàn-ìn tí epo dì mọ́
2 Ibawò : Ibi tí à ń kó odi ẹyìn jọ sí
3. Eyìn ṣíṣí : Mímú ẹyìn kúrò lára ṣọṣọ
4. Ẹyìn títẹ̀ : Fífi ẹsẹ̀ tẹ ẹyìn tí a ti sè jinná
5. Ètìtán : Ẹyìn kékeré tó jẹ́ kìkì epo

## 4.2 Ìpín Kejì

**Yánkò tàbí Àdí ṣíṣe**

Tí a bá pa èkùrọ́ tán, tí a mú eésan kúrò lára rẹ̀ tán, a ó da èkùrọ́ sínú ìkòkò kan, a ó dáná sí i bẹ́ẹ̀. A ó máa fi ìgbakọ yi èkùrọ́ yìí tí ó bá ti di pé èkùrọ́ gbóná dáadáa. A ó máa koná mọ́ ọ dáàdáa. Tí a bá rí i pé èkùrọ́ yìí ti paradà dáadáa, a ó gbọ́n ọn kúrò nínú ìkòkò, a ó dà á sínú odó, a ó bẹ̀rẹ̀ sí gún un. Tí ó bá kúnná, a ó dà á sínú ìkòkò, a ó tún dá iná mọ́ ọn dáadáa. Láti ìgbà yìí ni a ó ti ṣe àkíyèsí pé yánkò ti ń fó sí òkè, a ó wá máa fi igbá kan ré èyí ti ń fo sókè sí ibìkan. Lẹ́yìn tí a bá ti ré èyí tí ó ṣe é ré tán, a ó gbọ́n ìyókù kúrò nínú ìkòkò, o di lílọ̀ lójú ọlọ. Tí èpò ti a ń lọ̀ yìí bá kúnná dáadáa a o pafẹ́fẹ́ rẹ̀ sínú igbá ńla kan ni alẹ́ kí a tó sùn.

Tí ó ba ti di ìdájí, a ó pọn omi sínu ìkòkò kan, á máa bu epo yánkò ti a ti pafẹ́fẹ́ lálẹ́ àná sínú odó, a ó ko ẹsẹ méjéèji sínú odó a ó máa fi ẹsẹ̀ yí i po, a ó sì máa bu omi sí i díẹ̀ díẹ. Bí a ti ń ṣe èyí ni èpò yánkò yóò máa ṣẹ́ funfun bọ̀, a ó máa kọrin báyìí:

> Ìyámàpó gbá mi o;
> Aṣọ tí modálẹ́sìn-í gbó-
> Ìyámapó gb̀ mí o;
> Aṣọ ti mo dá lẹsìn-ín gbó.

Báyìí ni a máa kọrin kí Ìyámapó le ṣíjú àánú wo ẹni tí ń ṣe yànkò, kí yánkò le jáde dáadáa. Báyìí ni a ó máa kọrin tití, tí a ó máa tẹ èpò yìí títí tí yóò fi ṣẹ́ funfun dáadáa. A ó tun da èyí tí a ti ré nígbà tí a n yan àdí mọ́ èyí tí a n tẹ̀ nínú odó tàbí kí a fi òhun sílẹ̀ bi àdí ẹyan. Tí epo bá ti ṣẹ́ funfun dáadáa, a ó gbọ́ ọn dà sínú ìkòkò, a ó wa bu ọ̀pọ̀ omi lé e lórí, a ó fi ọwọ́ rú u pọ̀. Bí a ti ń ṣe èyí ni yánkò yóò máa léfòó, a ó sì máa ré e

sínú igbá kan. Tí a bá ré e tán, a ó tún dà á sínú ìkòkò kan lórí ààrò, a ó wa dáná sí i. O wá di sísè tí yóò jinná dáadáa, tí omi yóò ti gbẹ lara rẹ̀. Tí a bá fẹ́ mọ̀ bí omi tigbẹ tàbí kò ì gbẹ, a ó já ewé ọdán tútù, a o fi bọ inú rẹ̀, a ó tètè yọ ọ́ jade; tí yánkò bá jinná ewé yìí yóò jóná hùn-ùn ni. Tí ó ba ti dà báyìí, a ó tètè gbọ́n yánkò náà kúrò lórí iná nítorí kí ó máa bàa gbiná nínu ìkòkò. A ó wá dà á sínú ìkòkò adípe (ìkòkò kékeré tí kò jìn lójú) kan kí afẹ́fẹ́ fẹ́ sí i. Bí ó ti ń tutù niyóò máa dì. Tí ó bá dì tán, ó kù kí a kọ ọ́, èyí ni ki a fi ọbẹ gé e sí òdiwòn kèèkéékèè ti a ó máa tà á.

## 4.3 Ìpín Kẹta

### 4.3.1 Orì Kíkọ

A ń fi epo àti yánko tanná, bẹ́ẹ̀ ni a sì ń lò ó fún ohun mìíràn. Ẹ̀ẹ̀kẹta ohun tí a tún fi ń tanná ni òrí. Ní ilẹ pápá tàbí ọ̀dàn paraku ni igi ẹmì tí ó ń so èso tí a fi ńṣe òrí ń gbé. Nítorí náà òrí ni ó dípò epo fún àwọn tí ń gbé ilẹ̀ ọ̀dàn. Àkókò ẹ̀rùn ni a máa ń rí èèsè ṣà nídìí ẹmi. Tí a bá ṣa èèsè tán, a ó pa èèpo ara rẹ̀, lẹ́yìn èyí ó di síse lórí iná. Tí o ba jinná dáadáa, a ó wà á; a ó lọ sá a sí orí ibi tí ó bá tẹ́jú tí òòrùn yóò ti pá á dáadáa. Tí ó ba gbẹ, a ó pa èèpo ara rẹ̀ kúrò, a ó tun dà á sínú ìkòkò, a ó sè é jinná dáadaa, èèsè yóò ti pa awọ̀ dà nínú ìkòkò. A ó wá gbọ́n ọn sínú ìkòkò àbí koto alájere (tí ó lu fóófóófóó) kan, a ó gbé e ka orí ìkòkò adípẹ kan, omi ara èèsè tí a se yóò ḿaa ro sínú ìkòkò yìí. Tí ó bá ro tán, èèsè di gígún nínú odó; lẹ́yìn náà, a ó máa fi orógùn rò ó pọ̀. Bí a ti ń rò ó yìí ni yóò bẹ̀rẹ̀ sí i le bọ̀ díẹ̀díẹ̀. Lẹ́yìn náà, a ó bu omi sí i, a ó máa rò ó pọ̀. Bí a ti ń bu omi sì í yìí ni òrí yóò máa léfòó, tí a ó sì máa fi ọwọ́ ré e sínu ìkòkò kan. Tí a bá ré e tán, a ó dáná sí ìkòkò yìí, ti òrí yóò máa hó putuputu nínú rẹ̀. ti ó bá jinná, a ó sọ̀ ọ́ kalẹ̀, a ó da òrí yìí sínú ìkòkò kan tí a ti fọ̀mọ́ dáadáa. A ó máa rò ó pọ̀ nínú ìkòkò yìí, yóò sì bẹ̀rẹ̀ sí le bí afẹ́fẹ́ ti ń fẹ́ sí i, yóò wá dàbí ẹ̀kọ. ó ku kí á tẹ́ ewé sínú àdému tàbí ahá kí a máa bu orí yìí sínú rẹ̀, kí a máa pọ́n ọn bí ẹ̀kọ. Tí ó bá tutù, yóò wa le kongi; a ó wá yọ ọ́ nínú àdému, orí di lílò bí a ṣe fẹ́. Òrí tó wa bọrọgidi tí a jà lókùn ni à ń pè ní kòtòkoto òrí.

#### 4.3.1.1 Àkíyèsí

A kò gbọdọ̀ sọ̀rọ̀ nígbà tí a bá ń gún èèse; obìnrin kò sì gbọdọ̀ bá ọkọ rẹ̀ jà tàbí kí ó ní ìkùnsínú kan sí ẹnikan nígbà tí ó bá ń ṣe òrí nítorí kí Ìyámàpó le wáyée're. Èyí tún ń tọ́ka sí ìgbàgbọ́ àwọnYorùbá yàtọ̀ sí ẹ̀sìn pé, ènìyàn kò le retí àyọrísí ire nígbà tí inú rẹ̀ kò mọ́ sí ọmọnìkejì rẹ̀.

### 4.3.2 Aró Dídá

A ó tọ́jú lábúlábú tí wọn sun dáadáa pẹ̀lú eérú ojú ààrò. A ó po méjèèjì pọ̀. Bí a ti ń pò wọ́n pọ̀ ni a ó máa fi omi wọ́n ọn kí ó le parapọ̀ dáadáa. Lẹ́yìn náà ni a ó tọ́jú elékìtì- ìkòkò méjì ní èyí. Ìkòkò àkọ́kọ́ ri bí ìkòkò

gidi, ṣùgbọ́n a ya á léti láti òkè dé ìdajì òòró ìkòkò náà. ìkòkò kejì náà kò yàtọ̀ sí ìkòkò gidi ṣùgbọ́n a lu ìdí rẹ̀ díẹ̀, o le fẹ̀ tó nǹkan tí ọmọrí odó yóò fi le wọ̀ ọ́. Èyí ni à ń pè ni àládìro. (Àwọn ìkòkò méjéèjì ni à ń pè ni elékìtì). A ó to igi kéékèèkéé yí ihò ìdí aládìro, a ó ja koríko lé e, a ó gbé e ka orí ìkòkò kejì.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mẹ́nu bà á ní tẹ̀lẹ̀, ìgbà ti ìyá aláró bá délé ni yóò wa to igi àti koríko sínú aládirò (ààro). Yóò mú eérú ojú adàro díẹ̀, yóo dà á pọ̀ mọ́ lábúlábú láti dín agbára lábúlábú kù kí ó má ba à gé ẹ̀lú àti aṣọ tí a bá fẹ́ rẹ wẹ̀lẹ́wẹ̀lẹ̀. Bí ó ti ń da eérú yìí pọ̀ mọ́ lábúlábú ni yóò máa fi òkùṣú aró pò ó pọ̀ ní orí ilẹ̀ẹ̀lẹ̀. Yóò máa fi ba ahọ́n láti dán an wò bí o ti mú tó. Tí ó bá mú tó bí ó ti ń fẹ́, yóò da lábúlábú sínú aládìrò, yóò rọra máa bu omi tútù sí i lórí títí tí omi yóò fi máa kán tó, tó, tó, sínú ìkòkò tí a fi gbè é ní ìsàlẹ̀. Tí èèyàn bá mu ún, kò le ṣe ìsẹ́jú méjì tí ìfun rẹ̀ yóò fi gé wẹ̀lẹ́wẹ̀lé. Èyí ni à ń pè ní ọ̀gangan aró. Tí ó bá di pé agbára omi aró yìí ń dínkù, ẹwọ aró ni a ń pè é bí elékìtì, (èyí ni lábúlábú tutú nínú aládìro) bá di ẹ̀wọ̀ aró, a ní láti wọ elékìtì yìí, nítorí ko dára fún aró mọ́. Ọ̀ganganaró ni a fi ń dá omi aró, gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣáájú.

Ọ̀pá tí a fi ń ro aró nínú ìkòkò aró ni à ń pè ní ọ̀pá aró. Orí pááfà ni a ń na aṣọ ànàrẹ sí, (èyí ni aṣọ tí a ń yọ nínú aró ti a ń nà sórí pááfá); Yorùbá ń pe ọfọ̀ pé 'ọ̀pá aró kì í bá aró kú', nítorí pé a le fi ọ̀pá aró kan rẹ ju ogójì ìkòko aró lọ. A kò gbọdọ̀ fi aṣọ sínú aró gbàrà tí a ba ti dá aró tán. A ó fi igbá oko ti ó dé ìkòkò aró dáadáa bò ó. Tí ó bá tó ọjọ́ kẹta bí a ó máa ṣí aró yìí wò, a ó ma wo ojú rẹ̀, a ó fi ọwọ́ wò bóyá ó mú aṣọ. ibí yìí ni òwe yìí ti jáde pé, 'Ẹni tó ń daró ni aró aró-ó kọ̀kọ̀ mú kí ó tó mú aṣọ rẹ̀'. Níjọ́ tí a bá ṣi ìkòkò aró tí ojú rẹ̀ sì kọ yèréyèrè bí igbá tí epo wà lójú omi, níjọ́ tí a bá ti ọwọ́ bọ aró tó mú ọwọ́, tí a fi dán aṣọ wò, to mú aṣọ, ojó náà ni aró jáde, ọjọ́ náà ni a ó sì bẹ̀rẹ̀ sí rẹ asọ nínú rẹ̀. Èyí a máa gbà tó ọjọ́ kẹta sí ọjọ́ karùn-ún. (Tí aró kò bá jáde lákòókò yìí a ó rí i pé aró náà yóò wú, a ó sì sọ pé aró náà bàjẹ́: lábúlábú kò dára ló máa ń fa èyí).



Tí aṣọ bá wá nínú aró, a ó jókòó tì í, a ó máa fi ọwọ́ yí aṣọ yìí po, a ó máa nà án sínú aró, a ó tún máa yí i po. Tí a bá ṣe eyí díẹ̀, a ó fi aṣọ sílẹ̀ nínú aró fún bíi ìṣẹ́jú mẹ́wàá, a ó wa yọ ó le orí ibi tí ó tẹ́jú fún bíi ìṣẹ́jú márùn-ún sí mẹ́wàá kí á tún tó kì í sínú aró, ṣíṣe báyìí ni a ń pè ni aró-rírẹ. A ó tún máa rẹ ẹ́ nínú rẹ̀, a ó sì máa yọ ọ́ síta láti sá a. Báyìí ni a ó máa ṣe títí aṣọ tí à ń rẹ yóò fi dúdú tó bí a ti ń fẹ́. A le rẹ ẹ́ kí ó dúdú díẹ̀, èyí ni a ń pè ní ẹ̀pa tàbí ṣóláró, a sì le rẹ ẹ́ kí ó dúdú, èyí ni a ń pè ni à

## 4.3.2.1 Lábúlábú

A ti sọ pé lábúlábú ni a fi ń dá aró, ó yẹ kí á mọ bí a ṣe ń ṣelábúlábú. Ojúlówó iṣẹ́ àwọn obìnrin kan ni lábúlábú ṣíṣe jẹ́. Ibi tí a ti ń ṣe lábúlábu ni a ń pè ni ẹbu lábúlábú. Tí a bá fẹ́ ṣe lábúlábú a ó mọ ilé kan bíríkótó, yóò ga tó ẹsẹ̀ bàtà márùn-ún, yóò sì fẹ̀ tó ẹsẹ̀ bàtà mẹ́rin, yóò ri róbótó bí ilé ọni; ṣùgbọ́n a ó lu ojú méjì sí i ní ìsàlẹ̀. Kò ṣe, kò yàtọ̀ sí ilé isunlẹ̀ tí àwọn woléwolé ń mọ ríbítí-ríbítí nígbà kan. Ilé tí wọn mọ yìí ni à ń pè ni **agà lábúlábú**. Lẹ́yìn agà yìí, àwọn ohun tí a ó rí ni ẹbu lábúlábú ni àwọn odù ìkòkò bíi mẹ́wàá sí ogún, a ó tò wọn yí agà po.

Ohun tí ó tún kù tí a ó ṣe ni kí á máa kó eérú ààro jọ. A ó máa kó o sí ìta bí ìgbà tí a ń da ilẹ̀ sí àátàn ni a ó máa da eérú yìí léra wọn ni àdàlé-àdàlé. Àwọn igi kan tún wà ti eérú wọn máa ń dára; bí àpẹẹrẹ, eérú igi ìgbá. Tí a bá rí eérú igi báwọ̀nyí kó, oríire ni fún onílábúlábú nítorí ó máa ń mú lẹ́nu bíi kan-úngan-an ni. Tí a bá kó eérú yìí jọ, tí ó ga gèlètè, a ó lọ wá **òkùṣú aró** (òkú aró), èyí ni omi aró tí a rẹ tí o ti ṣá, a ó máa fi ro érú yìí bí ìgbà tí a ń ro erùpẹ̀ tí a fẹ́ fi mọ ilé. A ó wa ṣu eérú yìí rógódó rógódó bíi bàrà, a ó máa tò wọ́n sílẹ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan níta gbangba. A ó wá kó eérú tí a sù yìí sínú agà lọ́kọ̀ọ̀kan. A ó tò ó, yóò ga sókè; a ó wa ko **ṣákítí aró**, èyí ni èyí tí ó ṣẹ́kù nínú ẹ̀lú tí a ti lò fún aró-rírẹ tẹ́lẹ̀, tí kò le mú aṣọ mọ́; a ó kó o bò ó lórí mọ́ inú agà, a ó fi àpáàdì ńláńlá bogbogbo rẹ̀ pọ̀ mọ́ inú agà. A o kó igi títóbi sí ojú iho ḿjéèjì tí a dá sí ìsàlẹ̀ agà, a ó wá dáná sí i sàn-án-sàn-án. Iná yìí yóò pọ̀ tóbẹ́ẹ̀ tó fi jẹ pé ti èniyàn bá ń súnmọ́ ọn bíi ẹsẹ̀ bàtà mẹ́wàá ni yóò ti máa ra èniyàn lára. Iná yìí ni à ń pè ni iná ìléru. Talẹ̀-tàárọ̀ ni iná yìí yóò máa kẹ̀, àìsùn ni a ó ṣe tì í pẹ̀lú, nítorí pé iná kò gbọdọ̀ lọ sílẹ̀ ní idí rẹ̀ tí a bá fẹ́ kí lábúlábú yìí jáde dáadáa., tí lábúlábú kò bá sì mú, kò sí bí a ti le fi ẹ̀lú dá aró tí yóò rẹ aṣọ, kí ó fi dúdú. Aró páà kò ní rẹṣẹ rárá. Tọsán-tòru, a ó máa dá iná sí eérú yìí, òmíràn ń tó ọjọ́ karùn-ún pẹ̀lú, ó di ìgbà tí eérú yìí bá mú awọ lábúlábú jáde kí a tó dáwọ́ iná-ìléruyìí dúró.

Lẹ́yìn tí eérú bá ti mú àwọ̀ lábúlábú jáde, ọjọ́ mẹ́ta gbáko ni a ó tún máa bu òkúsú aró sí inú eérú tó wà nínú agà. Aájò kí lábúlábú le mú náá ni. a kì í dá lábúĺabú ni àkókò òjò nítorí kí omi òjò má ba eérú yìí jẹ. Tí érú tí a lò láti fi ṣe lábúlábu yìí bá dára, tí òjò kò sì pa á lórí agà, tí iná kò sì yẹ niìdí rẹ̀ tọsán-tòru, tí èniyàn bá fi ọwọ́ lábúlábu yìí kan ẹnu, gógógó ni yóò mú lẹ́nu bíi káń-un akọ (bílálà). Ìgbà yìí ni a ń sọ pé lábúlábú jáde

dáadáa (lábúlábú mù). Tí lábúlábú yìí bá tutù, a ó máa kó o nínú agà, a ó máa dà á sínú awọn odù ìkòkò, a le kò lábúlábú mẹ́wàá sí ogún sínú odù kọ̀ọ̀kan. Ẹni tí ó bá fẹ́ dá aró ni yóò maa rá lábúlábu yìí. Òsùwọn ìgbá ni a fi ń tà á. Ìyá aláro le ra òṣùwọ̀n mẹ́ta, ó le ra mẹ́wàá, bi ìkòkò aró rẹ̀ bá ti tóbi sí ni.

## 3.3 Ìpín Kẹta

### 3.3.1 Iṣé Irin Sísun

Iṣẹ́ irin sísun jẹ́ ọkan nínú iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe kí Òyìnbó tó kó irin tiwọn dé ilẹ̀ Yorùbá. Láti ìgbà tí àwọn Yorùbá ti wà ní Ìdòròmù Ìwáṣẹ̀ ni àwọn ìran wọn ti máa ń ṣe iṣẹ́ irin sísun. Láàma ni baba ńlá àwọn Yorùbá tí ó kọ́kọ́ dá iṣẹ́ irin sísun sílẹ̀ ní Ìdòròmù ìwáṣẹ̀, tí ó sì kọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìran rẹ̀. Àwọn tí ó máa ń ṣe iṣẹ́ irin sísun ni à ń pè ní **Onípọ̀n-ọ́nrin** . Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé Ògún Lákáayé ni ó dá iṣẹ́ yìí sílẹ̀ ní ilẹ̀ Òkè Odò ọya, tí à ń pè ní ilẹ̀ ènìyàn dúdú.

Àwọn òkúta wọ́bọ́wọ́bọ́ tí à ń pè nim Káró tàbí Òkúta Òkúrú pupa ni à ń sun tí ó ń di irin. Oríṣi mẹ́ta ni àwọn òkúta tí à ń wí yìí. Orúkọ tí àwọn Onípọ̀n-ọ́nrin ń àwọn òkúta Òkúrú yìí ni ẹ̀ta irin, orúkọ tí a mọ̀ wọ́n sí ni:

1. Ẹ̀ta Sàgodo
2. Ẹ̀ta Òkò tàbí Ẹ̀ta Afúyẹ́
3. Ẹ̀ta Agúnwínwín

A lè rí irú ẹ̀ta kìíní tí à ń pè ní Sàgodo yìí ṣà lórí ilẹ̀ bí òjò bá ń rọ̀ tí àgbàrá sì ń wọ́ yanrìn kúrò lórí wọn. Ẹni tí ó bá ti dá irú òkúta yìí mọ̀ yóó kàn máa ṣà á ni.Irú òkúta yìí ni ó sì ní irin nínú jù nígbà tí a bá sun wọ́n, irin tí a bá sì mú jáde láti ara wọn ni ó máa ń dára jù. Wíwà ni à ń wa ẹ̀ta òkò àti agúnwínwín, ṣùgbọ́n agúnwínwín wẹ́ ju ẹ̀ta òkò lọ. Èédú ni wọ́n fi ń dáná tí wọ́n fi ń sun òkúta Káró tí wọ́n ń pè ní ẹ̀ta irin, èyí tí ó fi máa ń di irin. Kìí ṣe èédú igi lásán kan ni a fi ń dáná irin, bí kò ṣe èédú àwọn igi tí ó lágbára tí ó sì lóró, àwọn igi náà nìwọ̀yí:

1. **Igi Ẹ̀run**: Tí a tún ń pè ní igi Ọ̀bọ̀ , igi yìí ní oró débi pé a kìí jẹ èèpo àti egbò rẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni ó sì ní agbára láti sun ohunkóhun tí a bá fẹ́ fi sun jóná ráúráú.
2. **Igi Òrúpa dúdú tàbí akọ Òrúpa** : Èyí náà pàápàá ní oró bíi igi ẹ̀run, igi yìí ní agbára bíi akọ òkúta, nítorí náà ni wọ́n fi ń lò ó fún irin sísun.
3. **Igi Pọ́nhan:** Igi pọ́nhan jẹm igi líle paraku, èèpo rẹ̀ sì dàbí eésan èkùrọ́. Nítorí ìdí èyí, iná èèdú rẹ̀ pàápàá ní agbára láti jó nǹkan tí a bá fi sun, tàbí láti mú ohun tí a bá fi ṣe gbóná ju ìgbà tí a bá lo èédú igi mìíràn lọ

Báwo ni a ṣe ń koná mọ́ káró tó fi ń di irin? . Bí iná bá ní agbára tán, tí ó sì ràn dáadáa nínú ada ( ada ni à ń pè ní adodo tàbí ààrò irin), a ó kọ́kọ́ bu igbá tàbí agbọ̀n káró kan dà sínú rẹ̀. Lẹ́yìn bíi ogún ìṣẹ́jú, a ó tún bu apẹ̀rẹ̀ èédú bíi mẹ́ta sí inú rẹ̀, tí ó bá tún ṣe díẹ̀, a ó tún bu igbá tàbí apẹ̀rẹ̀ káró kan sí inú iná náà, a ó sì tún da èédú sí i. Báyìí ni a ó máa ṣe fún odidi ọjọ́ mẹ́ta gbáko láìdáwọ́dúró, ìdí nìyìí tí a fi ń pe iná tí a fi ń sun irin ní iná Ìléru tàbí iná Àjórun.

Lẹ́yìn ọjọ́ mẹ́ta tí a ti ń dá iná mọ òkúta náà, a ó dá ọwọ́ dúró ní àìdá iná mọ́ ọn mọ́. Ní ìgbà tí ó bá di ọjọ́ kejì tàbí ọjọ́ kẹta tí a kò ti dáná mọ́ ọn mọ́, a ó wá fi gọ̀gọ̀ irin tútù rú inú iná ààrò tí ó ti tutù, a ó sì wa irin àti idàrọ̀ ibẹ̀ jáde. Lẹ́yìn èyí irin ibẹ̀ yóò ti le, a ó sì kó idàrọ̀ dànù.

Èyí ni ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà sọ òkúta di irin. Irin yìí ni wọ́n fi ń rọ gbogbo ohuèlò tí a fi irin ṣe bíi àdá, ọ̀bẹ, ọkọ́ ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Irin sísun kò ṣàìní èèwọ̀, àwọn ohun tí kò gbọdọ̀ ṣẹlẹ̀ tí a bá ń sun irin lọ́wọ́ nìwọ̀nyí:

i) Obìnrin kò gbọdọ̀ wọ iléeṣẹ́ tí a ti ń sun irin , nítorí àwọn ìdí wọ̀nyí;

a) nítorí inú àwọn obìnrin mìíràn burú, a ní àwo.n tí wọ́n ń lo inú méjì, a sì ní àwọn tí wọ́n jẹ́ alágbára bíi àjẹ́,àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé wọ́n lè lo agbára wọn tàbí kí wọ́n ro èrò burúkú tí kò níí jẹ́ kí irin sun jiná

b) ìkejì ni pé, obìnrin tàbí ọkùnrin tí ó bá ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe eré ìfẹ́ tán ní ọjọ́ náà, tàbí ní nǹkan bí ọjọ́ méjì sẹ́yìn kò gbọdọ́ yọjú wo ehùrù tí a ti ń sun irin, níwọ̀n ìgbà tí ó sì ti ṣòro láti mọ irú ẹni bẹ́ẹ̀, ó sàn kí a ́ má wulẹ̀ gba obìnrin kankan láàyè láti wọ ibi tí a ti ń sun irin.

c) àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ògún kórìíra ìdọ̀tí, ó ṣeéṣe kí obìnrin máa ṣe nǹkan oṣù, wọ́n gbàgbọ́ pé iri tí à ń sun lọ́wọ́ lè bàjẹ́ tí ó bá gbóòórùn nǹkan oṣù

ii) Tí a bá fura sí ọkùnrin kan pé ó jẹ́ onínú méjì, a kò níí fún irú ọkùnrin bẹ́ẹ̀ ní ààyè láti wọ inú ehùrù tí a ti ń sun irin, èèwọ̀ ni fún irú ẹni bẹ́ẹ̀.

iii) A kò gbọdọ̀ fi epo pupa tan iná nigbà tí a bá kọ́kọ́ da irin sí inú iná, ìdí rẹ̀ ni pé àwọn agbára burúkú fẹ́ràn epo pupa, nítorí náà àdí tàbí òrí ni a máa ń lò láti tan iná, nítorí àwọn agbára burúkú yìí kò fi bẹ́ẹ̀ fẹ́ràn òrí àti àdí. Àdí tilẹ̀ jẹ́ èèwọ̀ fún Èṣù, tí ó jẹ́ olótùú àwọn agbára burúkú tí ń ba nǹkan jẹ́ yìí.

iv) A kìí wọ aṣọ pupa, tàbí aṣọ tí ó bá ní àwọ̀ pupa láààrín dúdú tàbí funfun,a kò sì tún gbọdọ̀ wọ aṣọ tí ó bá ní àwọ̀ ewé àti pupa. Asọ tí a ó bá wọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ dúdú délẹ̀ tàbí kí ó jẹ́ funfun délẹ̀, ṣùgbọ́n aṣọ dúdú ló dára jù.

v) A kò gbọdọ̀ fi orùka idẹ tàbí orùka bàbà bọ ọwọ́ nígbà tí a bá ń sun irin. Irin náà kò níí jiná, ṣe ni yóò kàn pọ́n lásán.

vi) Adìyẹ tàbí ewúrẹ́ kò gbọdọ̀ wọ ilé ìsunrin, àfi ajá, àgùntàn tàbí ẹyẹlé ni a lè gbà láàyè kí wọ́n wọlé, Yorùbá gbàgbọ́ pé àwọn ẹranko wọ̀nyí mọ́.

vii) Èèwọ̀ tí ó le jù ni pé, a kò gbọdọ̀ na ìko oódẹ sí iná ẹhùrù, ṣe ni irin náà yóó ya idẹ

Gbogbo ẹni tí ó bá ń ṣe iṣẹ́ irin sísun ló gbọ́dọ̀ mọ àwọn èèwọ̀ wọ̀nyí, kí iṣẹ́ irin tí wọ́n yàn láàyò lè máa ṣe dáadáa. Gẹ́gẹ́ bí i akẹ́kọ̀ọ́ èdè àti àṣà Yorùbá, ìwọ náà nílò látí ní òyè rẹ̀, nítorí gbogbo ohun tí a bá pè ní èèwọ̀ yẹ ní pípamọ́, ẹni tí ó bá sì pa èèwọ̀ mọ́ kò níí kó sínú wàhálà.

### 3.3.1.1 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Inú Iṣẹ́ Irin Sísun

1. Ada : Àárò ìsunrin
2. Àkàsọ̀ : Nǹkan tí a lè fi gun ibi tí ó bá ga nínú ilé ìsunrin
3. Arárà : Orí ibi tí a mọ àárò ìsunrin sí
4. Búlà : Imí Ẹṣin àti màálù tí a gún mọ́ èédú tí a sá gbẹ, tí a sì lọ lúbúlúbú, orí rẹ̀d ni a ó tẹ odù Ògúndá sí kí a ́ tó bẹ̀rẹ̀ sí níí dáná irin
5. Ẹbu-Ìsunrin : Ibi tim a ti ń sun irin a tún ń pè é ní ẹhùrù ìsunrin.
6. Ẹyín : Eléyìí ni èédú tí a fi ń sun irin
7. Fìtílà : Iná àtijọ́ kan tí a fi ìkòkò mọ
8. Ganmu-gánmú : Irin iṣẹ́ tí a fi ń ṣá ilẹ̀ kí á lè rí irin wà jáde.
9. Ìdàrọ́ : Èyí tí kò wúlò mọ́ lẹ́yìn tí a sun irin tán
10. Igi Ẹ̀run : Akọ igi tí a fi ńsun èédú láti fi sun irin
11. Igi Òrúpa dúdú : Akọ igi tí a fi ń sun èédú láti fi sun irin.
12. Igi Pọ́nhan : Akọ igi tí a fi ń sun èédú láti fi sun irin.
13. Iná Àjórun : Iná tí a fi ń sun irin fún ìgbà pípẹ́ a tún ń pè é ní iná ìléru
14. Irin sísun : Àlùmọ́nì ilẹ̀ tí a sun di òjé, bàbà, irin dúdú, wúrà àti irin mìíràn
15. Ìtùfú wàápà : Ẹ̀yìn ọ̀wá gbígbẹ tí a ya lára igi ògùrọ̀ tí a dì pọ̀ láti fi tan iná. Ó gùn ju ògùṣọ̀ lọ. A tún ń pè é ní apàrà
16. Káró : Èyí ni àwọn òkúta wọ́bọ́wọ́bọ́ tí a sun di irin. Ó tún ń jẹ́ òkúta òkúrú pupa tàbí ẹ̀ta irin. Mẹ́ta ni àwọn òkúta yìí: ẹ̀ta sàgodo, ẹ̀ta afúyẹm àti ẹ̀ta agúnwínwín
17. Kúdùúsù : Ohun èlò tí a fi ń wú ilẹ̀ tàbí wú gbòǹgbò tí a bá fẹ́ wa irin
18. Kòtò èta : Ilẹ̀ tí a gbẹ́ láti wa irin . Tí ó bá jìn lọ ilẹ̀ tàárà, a ó pè é ní ***ògìdo***, ṣùgbọ́n tí ó bá wà ní ìbúǹbú, a ó pè é ní ***ìpẹ́ẹ̀bú***
19. Láàmà : Ni ẹni àkọ́kọ́ tí ó ṣe iṣẹ́ irin sísun
20. Ojú-awà : Ojú ibi tí a dáná sí tí a fi ń sun irin
21. Onípọ̀-ọ̀nrin : Àwọn tí wọ́n ń ṣe iṣẹ́ irin sísun.

### 3.3.2 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ / Arọ́

Iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ tí a tún mọ̀ sí iṣẹ́ arọ́ jẹ́ iṣẹ́ ààrọ̀ àwọn Yorùbá. Ìwádìí fihàn pé ọ̀nà mẹ́ta ni iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ pín sí. Àwọn náà ni:
a) àgbẹ̀dẹ ọlọ́kọ

b) àgbẹ̀dẹ bàbà
d) àgbẹ̀dẹ oníbọn

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni àwọn àgbẹ̀dẹ máa ń mú ọ̀kan nínú àwọn àgbẹ̀dẹ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ní ààyò, ó ṣe é ṣe kí á rí alágbẹ̀dẹ tí ó mọ̀ nípa mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. Ní tòótọ ni iṣẹ́ àgbẹdẹ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta jọ ni ohun púpọ̀ papọ̀ nípa irin iṣé, ohun èlò àti nípa ètò ìtajà wọn, síbẹ̀ òkọ̀ọ̀kan wọn yàtò sí ara wọn. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìi, a ó gbìyànjú láti ṣe àlàyé Àgbẹ̀dẹ ọlọ́kọ́ nìkan, nítorí díẹ̀ náà ni àwọn yòókù fi yàtọ̀

### 3.3.2.1 Àgbẹ̀dẹ Ọlọ́kọ́

Kì í ṣe ọkọ́ nìkan ni àwọn àgbẹ̀dẹ yìí ń rọ gẹ́gẹ́ bí orúkọ wọn ṣe fihàn, ṣùgbọ́n a fi ọkọ́ pe orí wọn nítorí ọkọ jẹ ọkan pàtàkì lára ohun tí wọ́n ń rọ, ọkọ́ sì tún jẹ́ ohun èlò pàtàkì fún àwọn àgbẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá. Nítorí náà ohun tí àwọn àgbẹ̀dẹ yìí ń rọ pọ̀.

Nínú odù Ifá Ọ̀wónrí yẹ̀kú, Ifá sọ pé gbogbo ọmọ tí ẹwìrì tí í ṣe ìyàwó Ògùn bí fún Ògún ni àwọn àgbẹ̀dẹ ń mójú tó nínú iṣẹ́ wọn. Àwọn bí i :

a) ààké
b) ògígí ọsanyìn
d) ọkọ́
e) àdá
ẹ) ọ̀bẹ
f) ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀
g) dòjé
gb) ọ̀kọ̀
h)idà
i)kẹ́ṣẹ́ ẹṣin
j)ọfà
k) ọmọ oóbọ
l) agogo
m) ìlu
n) ẹ̀mú
o) abẹ́rẹ́
ọ) tàkúté àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

Ní ayé àtijọ́ kókó irin tútù ni àwọn àgbẹ̀dẹ máa ń lò , ṣùgbọ́n ní ayé òde òní àwọn irin tí ó bá wúwo, tí ó sì le ni ara mọ́tò ni àwọn alágbẹ̀dẹ máa ń lò ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Irin líle yìí ni wọn yóò sì kì sí inú iná láti fi rọ ohunkóhun tí wọ́n bá fẹ́. Irin tí a wà jáde láti inú ilẹ̀ ni àgbẹ̀dẹ ń lò ní àtijọ́. Irin tí a wà jáde nínú ilẹ̀ tí a kò tíì sun ni à ń pè ní ẹ̀ta, gẹ́gẹ́ bí a ti sọ nígbà tí à ń ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa sísun irin.

Mẹ́ta ni ẹ̀ta yìí, èyí tí a sọ pé ó dára jù nínú mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà ni ẹ̀ta ṣàgodo tí a tún mọ̀ sí ẹ̀ta afúyẹ́. Tí a bá fẹm sun ẹ̀ta, a ó wá àwọn igi líle bíi òrúpa, ọ̀bọ̀ àti pọ́nhan, a ó da ẹ̀ta tí a ti gbọn erùpẹ̀ kúrò lára rẹ sí inú ihò ńlá tí a

gbẹ́ fún irin sisún tí a sì ti dáná sí. Ọjọ́ méjì ni a ó fi dáná sí i , ọjọ́ kejì ni a ó yọ àwọn irin náà jáde, nígbàtí ó bá tutù tán ló tó di kókó irin. Bí kókó irin kod bá jinná, bí àgbẹ̀dẹ bá rà á, tí ó bá fi sínú iná , ṣe ni yóó máa ta pàràpàrà, ohunkóhun tí a bá sì fi irú irin bẹ́ẹ̀ rọ kò níí dára rárá
Bí àgbẹ̀dẹ bá fẹ́ rọ ọkọ́, yóò fi ìkọ́ gé irin tí ó fẹ́ lò, tí wọ́n bá fi ẹnu ìkọm náà lé irin, wọ́n á wá máa fi iriǹ mìíràn tí à ń pè ní òòlù lù ú. Irin tí wọn yóò gé kò níí fẹ̀ ju àtẹ́lẹwọ́ lọ Irin yìí ni wọn yóò máa fi iná ẹwìrì finná mọ. Lẹ́yìn tí a bá ti fi iná ẹwìrid finná mọ́ ọkọm tán, tí irin náà sì ti pọ́n wẹ̀ẹ̀, a ó fi ẹ̀mú mú un jáde láti inú iná lọ sí orí àpáta ńlá tí ówà ní àgbẹ̀dẹ tí à ń pè ní Ògún, níbẹ̀ ni wọn yóò ti máa fi ìyá-owú lù ù láti fi ṣe irin ọkọ́. Irù ọkọm ni àwọn alágbẹ̀dẹ kọmkọ́ máa ń yọ lára irin ọkọ́, ìrù ọkọ́ yìí ni irin ṣọbọlọ tí ó gùn díẹ̀ tí ó máa ń wọ inú ẹ̀rúkọ́( igi ọkọ́) . Lẹ́yìn náà ni wọn ó ò gbá igi ọkọ́ náà lọ̀tùn-ún lósì, wọn ó ò gbọ̀n ọ́n lẹ́nu kí ó lè mú dáadáa. Ó ṣe é ṣe kí irin náà ti tutù ní àsìkò yìí, a ó tún ki irin náà bọ inú iná kí ó lè nà , bí iṣẹ́ bá ti parí lórí ọkọ́ náà tí ó ti rí bí a ṣe fẹ́ kí ó rí, wọn yọ̀ò jù ú sínú ìkòkò omi tó wà ní àgbẹ̀dẹ tí à ń pè ní ìkòkò omi Ògún, èyí rí bẹ́ẹ̀ kí irin tí a rọ náà má baà máa dá tàbí kí ó máa yìnrìn tí a bá ń lò ó. Kí ọkọ́ lè ṣe é roko dáadáa, àgbẹ̀dẹ yóò tún irin náà kì sí inú iná, àyà rẹ̀ ni wọn yóò dà dé iná ní àsìkò yìí, tí ó bá ti pọ́n tán, wọn yóò jìn ín láyà sínú kí ó lè ṣe é roko dáadáa. Àgbẹ̀dẹ yóò ti wá ẹ̀rúkọ́ sílẹ̀, wọn yóò fi irin kan tí à ń pè ní ìlu lu ọrùn ẹ̀rúkọ́ yìí lọnà tí kò fi níí wọ́ rárá, lẹ́yìn èyí ni wọn yóò tún ti ìrù ọkọ́ bọ iná, tí ó bá ti pọ́n wẹ̀ẹ̀, , wọn yóò kì í bọ inú ẹ̀rúkọ́ náà, wọn ó sì tẹ ìrù irin-ọkọ́ tó yọ lẹ́yìn ọkọ́ mólẹd, kí ó má ba à yọ jábọ.

Oríṣi ọkọ́ méjì ni ó wà tí àwọn àgbẹ̀dẹ ń rọ, ọ̀kan ni ọkọm kékeré tí a fi ń roko lásán, èkejì ni ọkọ́ ńlá,tí a fi ń kọ ilẹ̀ ọkọ́ yìí ni a tún ń pè ní àkẹtun. Gbogbo àrà tí àwọn alágbẹ̀dẹ ń dá yìí niàwọn Yorùbá fi ń kì wọn pé:
Bí kò sí alágbẹ̀dẹ
A ò roko
Bí kò sí alágbẹ̀dẹ
A ò yẹ̀nà
Bí kò sí alágbẹ̀dẹ
A ò ti igba ẹrú ṣáájú

Àgbẹ̀dẹ ló ń rọ ọkọ́ bí a ti rí i nínú àlàyé tí a ṣe ṣáájú, àwọn ni wọ́n ń rọ àdà tí a fi ń ṣán oko, tí a sì fi ń yẹ̀nà, àwọn náà ló ń rọ ẹ̀wọ̀n tí a fi ń so ẹrú tí a bá mú bọ̀ láti ojú ogun, tí wọn kò fi ní lè sá lọ. Bí alágbẹ̀dẹ bá fẹ́ rọ èyíkéyìí nínú ohun tí àgbẹ̀dẹ ọlọ́kọ́ ń rọ, bí ó ṣe rọ ọkọ́ náà ni yóó tẹ̀lé láti rọ agogo, ọ̀bẹ, idà àti àwọn yòókù.

### 3.3.2.2 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò Inú Iṣẹ́ Arọ́

1. Àáké boro : Kò yàtọ̀ sí àáké tí a fi ń la igi, ìyàtọ̀ rẹ̀ ni pé àáké yìí kéré ju àáké ìlagi lọ, ó kéré débi pé ọwọ́ kan ni a fi ń lò ó. A tún ń pe àáké yìí ní àhán

2. Àáyán : Akọ igi tí àwọn alágbẹ̀dẹ fi ń ṣe èédú
3. Abẹ-ìbọn : Irin pẹlẹbẹ tí a de àwọn nǹkan bí i , òòlù ìbọn, ìré ìdí ìbọn adti akó ìbọn mọ́
4. Àgbáǹdabùú : Irin pẹlẹbẹ tí à ń fi ọwọ́ gbé sókè tí a bá fẹ́ dẹ tàkúté
5. Àkànmọ́lẹ̀ : A máa ń lu irin lórí rẹ̀ ní àgbẹ̀dẹ. Irin ni, ó rí gbọọrọ , ó sì lágbára gan-an a wá rì í mọ́lẹ̀
6. Àkẹtun : Ọkọ́ ńlá tí a fi ń kọlẹ̀
7. Apátí ìbọn : Ibi tí irin ti máa ń lu ara wọn nígbà tí a bá yin ìbọn
8. Asàfà : Akọ igi tí adwọn alágbẹ̀dẹ fi ń ṣe èédú
9. Àyin : Akọ igi tí adwọn alágbẹddẹ fi ń ṣe èédú
10. Bọ́nà : Irin kékeré tí ó ní ihò tí à ń ha ìṣáná sí tí a bá fẹ́ yin ìbọn
11. Bùláà : Eléyìí rí lúbúlúbú bi i èlùbọ́, bí a bá dà á sí orí irin tí a sì fi iná sí i ,ṣe ni yóó so irin náà papọ̀ di ọkan. À ń lò ó láti fi jó irin pọ̀ ní àgbẹ̀dẹ
12. Èèkù : Igi tim a gbẹ́ sí ìdí ọ̀bẹ tàbí àdá
13. Eésan : Èèpo èkùrọ́ tí a ti sun
14. Egboro-ìbọn : Irin tim ó ní ihì tí a dè mọ́ ìdí ìbọn, níbẹ̀ ni à ń rọ ọta ìbọn sí
15. Ẹmú : Irin tí ó led padé tàbí kim ó lanu sílẹd, ó dá lórí bí a bá ṣe lò ó. Òhun ni àwọn àgbẹ̀dẹ fi ń mú irin gbígbóná ní àgbẹ̀dẹ
16. Ẹrúkọ́ : Igi ọkọ́ tí a máa ń dìmú tí a bá ń roko
17. Ẹwìrì : Edyí ni àwọn alágbẹ̀dẹ ń lò láti fi fín iná
18. Ìkọ́ : Irin tí ó mú lẹ́nu dáadáa , ohun ni wọ́n fi ń gé irin ní àgbẹ̀dẹ
19. Ìlu : Irin ṣọṣọrọ tí ẹnu rẹ̀ mú , òhun ni a fi ń lu nǹkan ní àgbẹ̀dẹ
20. Kóbíkóbí : Irin tín-ínrín tí à ń gbé òkùtẹ́ kọ́ lára tàkúté
21. Káàpù : òhun ni a máa ń kì bọ ẹnu bọ́nà ìbọn dípò kí a ha ìṣáná síbẹ̀
22. Ojú-awà : Ibi tí a dáná sí ní àgbẹ̀dẹ
23. Owú : Irin tó bá wúwo tìpìrì , oríṣi méjì ló wà; ọmọ owú àti ìyá owú
24. Orí-Ògun : Orí àpáta tí ó wà ní àgbẹ̀dẹ tí a ti ń lu irin
25. Gbigbọn lẹ́nu : Èyí ni fífi irin ńlá lu ẹnu irin , kí ó lè ba à mú

### 3.3.3 Iṣẹ́ Híhun Aṣọ Òfì

Ọ̀kan lára àwọn iṣẹ́ àtìrandíran Yorùbá ni iṣẹ́ aṣọ òfì híhun. Ó gbajúgbajà, ó sì lówó lórí. Òwú ìbílẹ̀ ni àwọn ahunṣọ fi máa ń hun kíjìpá tàbí aṣọ òkè. Wọ́n máa ń gbé oríṣiríìṣi fọ́nrán òwú fún àwọn aláró láti pa ní aró tó ki tàbí èyí tí yóò yọ fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́. Tó bá jẹ́ òwú funfun báláú ni, wọn kò ní pa á láró rárá.

Bí a bá fẹ́ hun òfì ọkùnrin, a ní láti lésè aṣọ. Bí a ṣe ń lésè aṣọ ni pé á ó gbé ẹrù òwú tí a ti ká, a ó wá máa ki fọ́nrán òwú kọ̀ọ̀kan nínú ẹrù òwú náà bọ inú ọmú-aṣọ, bí wọ́n ba ń ṣe èyí ni à ń pè ní Rírí òwú sójú ọmú òwú tín-ínrín tí a ran pọ̀, tí ó dàbí àwọn ni a fi ṣe ọmú-aṣọ. Lẹ́yìn tí a bá

ri òwú kọ̀ ọ̀kan bọ inú aṣàtí ó ní igun mẹ́rin tí a kan ọ̀wá tẹ́ẹ́rẹ́tẹ́ẹ́rẹ́ mọ́ nínú. Àko ni a fi ṣe aṣà, lẹ́yìn èyí kí á máa hun aṣọ ọkùnrin lọ ló kù.
Lẹ́yìn tí a ti lésè aṣọ tán, a ó tẹ́ ìtẹ̀sè, igi tẹ́ẹ́rẹm méjì ni a fi ṣe é, a ó so okùn ọmú aṣọ mọ́ ọn. Bí a bá fi ẹsẹ̀ te igi náà, òhun ni yóó fa ọmú-aṣọ wá sí ìsàlẹ̀, ní àsìkò kan náà ni Òkèékèé tó wà ní òkè yóò yí , bí òkèékèé kò bá yí lókè, òwú kò ní lanu sílẹ̀, àwọn méjèèjì jọ ń ṣisẹ́ papọ̀ ni. Lẹ́yìn tí òwú bá lanu sílẹ̀ tán, a ó mú ọkọ̀ tí a ti wé òwú mọ́ lára gba àárín òwú tí ó la ẹnu sílẹ̀ lẹ́yìn tí a ti tẹ ìtẹ̀sẹ̀, èyí ló ń jẹ́ pé à ń sọ ọ̀kọ́ aṣọ, bí a bá ṣe èyí tán ló wá kan Ààsà tí a ó fi kan aṣọ.

Bí a bá ti hun aṣọ jìnnà díẹ̀, a ó fi irin kékeré kan tí ẹnu rẹ̀ rí ṣọọrọ tí à ń pè ní ìyíṣọ, yí igi tí ó gùn díẹ̀ tí à ń pè ní Agbónrin, ara agbọ́nrin yìí ni aṣọ tí a ti hun tán yóò ká sí, báyìí ni a ó máa ṣe tí a ó fi hun aṣọ tán
Hihun aṣọ obìnrin yàtọ̀ sí ti ọkùnrin. Tí a bá fẹ́ hun aṣọ obìnrin, a ó kọ́kọ́ ta òwú kan ní òòró, èyí ni à ń pè ní òwú Irọ́. A ó tún ta òwú mìíràn ní ìbú, tí a mọd sí òwú ita. Tí a bá ti ṣe èyí tán , a ó wá máa wa aṣọ náà, èyí ni pé a ó máa fi ọwọ́ kan yẹ òwú aṣọ tí a ta, a ó sì máa fi ọwọ́ kejì sọ ọ̀kọ́ tí a ti wé òwú mọ́ lára gba àárín òwú tí a ta náà, a ó wá máa fi ọwọ́ méjèèji gbé apású tí a ó máa fi gbá a mọ́lẹ̀, báyìí ni a ó máa ṣe tí a ó fi hun aṣọ tán.

Ní ayé òde òní, aṣọ òfì híhun kò sí ní ipò ìmẹ́ẹ́rí rárá, níṣe ló dàbí ẹni pé àwọn ènìyan ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣíjú sí òfì lílò ju ti àtẹ̀yìnwá lọ. Oríṣirííṣi ni àrà tí àwọn ènìyàn lọ́. kùnrin àti lóbìnrin ń fi aṣọ òfì dá, pàápàá jùlọ àwọn ọ̀dọ́ lọ́kùnrin àti lóbìnrin. Ẹlòmíràn á fi rán kaba,ṣẹ́ẹ̀tì, síkẹ́ẹ̀tì àti bíláòsì, bákan náà ni wọn ń lò ó láti fi wé onírúurú àrà gèlè àti filà. Lílo aṣọ òfì jẹ́ kí àṣà Yorùbá túbọ̀ di mímọ̀ kákiri ayé, púpọ̀ ni àwọn tí ó sì ń kó aṣọ òfì lọ sí Òke-òkun fún títà. Aṣọ òfì gbajúmọ̀ ní ayé àtijọ́ , ó sì túbọ̀ ń gbajúmọ̀ sí i lóde òní.

### 3.3.3.1 Èdè Àmúlò Òfì Híhun

1. Ààsà : Ọ̀wá tẹ́ẹ́rẹm onígun mẹ́rin, ara rẹ̀ ni à ń fi òwú kọ́ bí a bá ń ta òfì
2. Àákọ́ òfì : Igi méjì tí a rì mọ́lẹ̀ tí a ta òwú tí a fẹ́ fi hun òfì ọkùnrin mọ́
3. Àbisi : Ààkò tẹ́ẹ́rẹ́ méjì tí a fi ń yẹ òwú tí a ta sí aṣọ òfì obìnrin
4. Agbọ́rin : Ohun ni à ń so aṣọ tí a so mọ́ ojú-ọmú àti ojú-aṣọ mọ́, pákó ni a fi gbẹ́ ẹ , ara rẹ̀ ni iyinṣọ wà
5. Ajáńdùbúlẹ̀ : Aṣọ tí omọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ ń hun ṣeré láti fi kọ́ṣẹ́
6. Àkáó : Igi ọparun tín-ínrín tí a ká òwú mọ́ lára.
7. Akata : Ó rí bí Òkòtó ṣùgbọ́n ó tóbi gan-an . Igi tí a mọ amọ̀ mọ́ lára ni , ara rẹ̀ ni a ti máa ń ká òwú, à ń pè é ní ọrùn ṣùgùdù nígbà mìíràn
8. Apásá : Igi tí a gbẹ́ tí ó dàbí idà, a fi ń hun aṣọ òfì obìnrin
9. Aṣẹmú : Àwọn tó ń ṣẹ́ ọmú fún aṣọ

10. Aṣọ wíwà : Fífi ọwọ́ kan yẹ òwú aṣọ òfì obìnrin tí a ta, kí á lè rí ààyè sọ ọ̀kọ́ sí ààrin rẹ̀
11. Àtù : Igi tí à ń ká òwú mọ́ fún híhun aṣọ obìnrin.
12. Ìdí òfì : Ibi tí a ti ń hun aṣọ tí a ta òfì sí
13. Ayé aṣọ kan : Tí à ń lò bí òṣùwọ̀n. Ó dàbí ọ̀pá aṣọ kan.
14. Ìdáàsà : Èyí tó bá ṣẹ́kù nínú aṣọ ò tí kò tó ayé aṣọ kan
15. Ìlẹ́ṣẹ̀ : Òwú yẹtuyẹtu tí ahunṣọ máa ń yọ sílẹ̀ kí ó tó bẹ̀rẹ̀ aṣọ híhun
16. Ìtàgè : Orí ibi tí à ń jókòó lé hun aṣọ, a tún máa ń pè é ní Tàgè
17. Ìtẹ̀sẹ̀ : Igi tẹ́ẹ́rẹ́ méjì tí a so okùn ọmú-aṣọ mọ́
18. Ìyinṣọ : Irin kékeré tó ṣe ẹnu ṣọọrọ, ara agbọ́nrin ló máa ń wà, ara rẹ̀ ni a máa ń ká aṣọ tí a bá ti hun tán sí
19. Kẹ̀kẹ́ : Igi tí a mọ amọ̀ mọ́ lára, tó dàbí òkòtó, ó máa ńyí bíríbírí bí a bá fi ń ran òwú
20. Kọkọgún : Irin tẹ́ẹ́rẹ́ tí ó ṣe orí rogodo, òhun ni a fi ń ká òwú lọ́rùn ṣùgùdù
21. Òkèékèé : Ó máa ń wà ní òkè orí ahunṣọ. Tim a bá ti tẹ ìtẹ̀sẹ̀ mọ́lẹ̀, yóó yí, yóó sì jẹ́ kí ọmú aṣọ lanu.

## 4.4 Ipín Kẹrin

### 4.4.1 Irú Fífọ̀.

Irú jẹ́ ohun èlò ọbẹ̀ tí ń mú kí ọbẹ̀ dùn lẹ́nu. Bí ẹ̀fọ́ bá dùn, irú ló pọ̀ níbẹ̀, bí ọbẹ̀ẹ́yọ̀ kan bá di àjẹfọ́wo, irú ló dùn ún.

Igi ìgbá ni o ń so èso ti a fi ń ṣe irú, ilẹ̀-ọ̀dàn ni a sì le ri igi ìgbá. Tí igi ìgbá bá so, ti èso rẹ̀ sì gbẹ, iṣẹ́ àwọn ọkùnrin ni láti lọ ká ìgbá, ti àwọn obìnrin ni láti rù ú lọ sí ilé. Ọkùnrin lè gun ìgbá láti ká a, wọ́n sì lè lo gọ̀gọ̀ láti fi ká a. Iṣẹ́ obìnrin paraku ni iṣẹ́ irú ṣíṣe.

Tí a bá dé ilé, a ó máa hó èèpo kúrò lára ọmọ ìgbá, a ó sì máa da ọmọ ìgbá yìí sínú apẹ̀rẹ̀ kan. Èèpo ìgbá yìí ni a ń pè ní ṣàṣàngbá; kò wúlò fún wa sùgbọ́n àwọn amọ̀kòkò a máa lò ó fún ìkòkò mímọ́. (A ó máa gbó nípa èyí nígbà tí a bá ń sọ nípa ìkòkò mímọ). Nígbà tí a bá hó ìgbá tan, a ó gbé e lọ sí odò láti fọ ẹfun ara ìgbá kúrò, yóò wá ku kóró ìgbá, èyí ni a ń pè ni ìyere. Tí a bá ṣe èyí tán, a ó da ìyere sínú ìkòkò ḿ́ẹ́yìn tí a bá ti sá a lóòrùn, tí ó gbẹ́ dáadáa. Ní ọjọ́ tí a bá fẹ́ ṣe irú, a ó da ìyere sínú ìkòkò, a ó bu omi sí i, a ó se e tí yóò jinná dáadáa gbogbo èèpo ara rẹ̀ yóo bú pẹ̀pẹ̀.



Lẹ́yìn èyí a ó da ìyere tí a ṣe sínú odó, a ó bu yanrìn kíkúnná sínú rẹ̀, a ó wa máa fi ẹsẹ̀ yiiri ìyere nínú odó, eèpo ara ìyere yóò máa bó. Tí èèpo yìí bá bó tán, a ó mú koto kékeré kan tí a ti lu bí ajere a ó máa da iyere tí a ti fọ̀ sínú rẹ̀, a ó máa fi ọwọ́ rò ó nínú koto. Àwọn èèpo yóò máa léfoó, yanrìn yóo sì máa gba iho ajere jáde a ó wá máa da ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sí ibìkan, èyí tí yóò mú èèpo kúrò lára rẹ yóò wá níbẹ̀ títí tí yóò fi gbẹ fúrúfúrú. Lẹ́yì èyí, a ó kò o sínú igbá-oko kan, a ó nà án fẹ̀lẹ́fẹ̀lẹ́ ká etí àti àárín igbá yìí. A ó ti lọ ọmọ ìṣápá sílẹ̀, yóò kúnná dáadáa. Èyí ni a ó bú le orí ọmọ irú tí a dà sínú igbá-oko. Lẹ́yìn èyí, a ó fi aṣọ bò ó, a ó tu fi igbá bò ó. Ó le tó ọjọ́ kẹtasí ọjọ́ kẹfà kí irú tó ṣẹ́ funfun dé, yóò sì máa run òórùn dídùn jáde tantan. Ìgbà yìí ni a máa ń wí pé ìyámàpó wáyée're. ó di kí á máa fi ìkakara tà á kiri fún àwọn ènìyàn. (Ìkakara ni ìkarahun ẹyìn ẹran omi inú òkun kan tí a fi ń ko irú, ó dàbí ọkọ̀ aṣọ) 'Ìyámàpó yóò wáyé e 're' ni à ń kí ẹnití ń ṣe irú.

Iṣẹ́ irú fífọ̀ kìí ṣe nǹkan tí èèyàn lè dédé kọ́ tàbí kò sí ní ọjọ́ kan láìjẹ́ pé onítọ̀hún ti fojú sí iṣẹ́ yìí lọ́dọ̀ àwọn tó mọ̀ nípa rẹ̀, iṣẹ́ yìí ní mímọ̀-ọ́n ṣe kí ènìyàn tó lè ṣe àṣeyọrí. Iṣẹ́ yìí kìí ṣe iṣe iṣẹ́ ìdílé, nítorí pé ẹnikẹ́ni tí ó bá nífẹ̀ẹ́ sí i ló ń kọ́ iṣẹ́ náà. Kò sí àkókò kan pàtó fún ẹni tí ó bá fẹ́ kọ́ iṣẹ́ irú fífọ̀, ó níí ṣe pẹ̀lú bí ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ bá ṣe tètè jáfáfá sí láti mọ iṣẹ́ náà ni. Bí ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ bá ti mọ iṣẹ́ náà dunjú, ohun tí ó kàn ni kí ó máa lọ dá iṣẹ́ tirẹ̀ náà ṣe lọ́tọ̀. Ọmọ tí ìyá rẹ̀ ń ṣe iṣẹ́ yìí náà sì lè fojú sí i láti kékeré, ohun tí ó ṣe pàtàkì ni pé iṣẹ́ yìí gba sùúrù àti àfiyèsí tí ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ bá fẹ́ ṣe àṣejèrè ní ìdí iṣẹ́ náà.

Tí irú ẹnìkan bá jáde dáadáa, tí ó sì dùn tayọ ti àwo.n ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù, ó ní láti jẹ́ pé irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ń pa àwọn èèwọ̀ iṣẹ́ yìí mọ́ ni. Àwọn èèwọ̀ wà fún ṣíṣe irú, àwọn èèwọ̀ náà nìwọ̀yí:

i). Tí obìnrin bá ń ṣe nǹkan oṣù re lọ́wọ́ kò gbọdọ̀ gba orí igi tí a fi ń ṣe irú kọjá nígbà tí a bá gbé irú kaná

ii). Ọkùnrin náà kò gbọdọ̀ gba orí igi yìí kọjá bákan náà. Ìdí ni pé, ọkùnrin mìíràn lè ṣẹ̀ṣẹ̀ bá obìnrin lò pọ̀ tán, kí ó sì má tí ì wẹ ara rẹ̀ nígbà tí ó ń gba orí igi náà, Yorùbá gbàgbọ́ pé irúfẹ́ ọkùnrin bẹ́ẹ̀ wà ní ipò kan náà pẹ̀lú obìnrin tí ó ń ṣe nǹkan oṣù lọ́wọ́.
iii). A kò gbọdọ̀ fọn iná ìdí irú nígbà tí a bá ń sè é lọ́wọ́
iv). A kò gbọdọ̀ sun ọ̀gẹ̀dẹ̀ tàbí bọ̀ọ̀lì nínú iná ti a bá ń se irú lọ́wọ́ .
v). A kò gbọdọ̀ lo odó , ọlọ àti igbá tí à ń lò fún iṣẹ́ irú láti fi ṣe nǹkan mìíràn bí i iyán gígún, ọkà rírò àti ata lílọ̀.

## 4.4.1.1 Àkíyèsí

Ohun tí a ṣe àkíyèsí ni pé, iṣẹ́ irú ṣíṣe ṣì gbajúmọ̀ ní àwùjọ wa lónìí, irú ṣì jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára èròjà ọbẹ̀ títí di bí a ṣe ń sọ̀rọ̀ yìí, nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ló fẹ́ràn láti máa fi irú se ọbẹ̀ wọn pàápàá, ọbẹ̀ ẹ̀fọ́. Irú a máa pẹ́ nílé tó bíi oṣù kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí a bá fi iyọ̀ sí i.

Àkíyèsí mìíràn ni pé, láàárín àwọn tí kò fi bẹ́ẹ̀ kàwé ni iṣẹ́ irú ṣíṣe àti títà ti wọ́pọ̀, àwọn tí a sì ń sọ yìí jẹ́ àgbàlagbà, wọn kìí ṣe ọ̀dọ́, ìwọ̀nba díẹ̀ ni àwọn tí ó jẹ́ ọdọ́bìnrin tí ó ń ta irú. Lóòótọ́, a ti ń rí àwọn kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ alákọ̀wé tí wọ́n ti ń fi iṣẹ́ irú ṣe òwò, àwọn mììràn a tilẹ̀ máa kó o lọ sí Òkè-òkun fún títà. Ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá tí o ti ní àǹfààní láti kọ́ nípa àṣà àti èdè Yorùbá ti ní ìmọ̀ nípa èèwọ̀ àti ọnà tí à ń gbà ṣe iṣẹ́ irú, o lè yan irú fífọ̀, ṣíṣe àti títà láàyò. Bákan náà, pẹ̀lú ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìwé tí o ti ni, o le lo ọgbọ́n ìmọ̀ sáyẹ́nsì àti ìmọ̀ ẹ̀rọ kọ̀npútà láti gbé okòwò rẹ lárugẹ, pàápàá lórí ẹ̀rọ ayélujára.

## 4.4.1.2 Díẹ̀ lára Èdè Àmúlò iṣẹ́ Irú Fífọ̀

1. Ajeere : Igbá tí inú rẹ̀ jìn kòtò tí a lu ihò sí fórofòro ní gbogbo ara láti fi fọ irú
2. À pótí irú : Àpóti tí a fi ń ta irú lọ́jà
3. Igi ìgbá : Igi tí a máa ń já ìyere tí a fi ń ṣe irú lórí rẹ̀
4. Irú pẹ̀tẹ̀ : Irú tó did pọd mọ́ ara wọn bí ègbo
5. Igbá irú : Igbá tí ó jinnú kòtò tí a fi ń ta irú lọ́jà
6. Bu irú pẹ̀tẹ̀ : Ká fi ṣíbí kékeré tàbí ìkarahun ìgbín òkun ta irú
7. Irú wooro : Irú tí kò dì pọ̀
8. Ikú irú : Èso igi kan báyìí tí a máa ń sọ sínú irú lórí iná láti jẹ́ kí ó rọ̀ pẹ̀tẹ̀pẹ̀tẹ̀
9. Ìyere : Èso igi ìgbá tí a fi ń ṣe irú
10. Lé irú wooro : Ká fi ṣíbí kékeré tàbí ìkarahun ìgbín òkun ta irú tí kò dì pọ̀
11. Ọpọ́n irú : Èyí ni nǹkan èlò tí à ń fọ irú sínú rẹ̀ létí odò

## 4.4.2 Ọtí Pípọn

A le fi àgbàdó tàbí ọkà-bàbà pọn ọtí, Ọtí àgbàdo ni à ń pè ni **ṣẹ̀kẹ̀tẹ** Ọti bàbà ni à ń pè ni **ọtíkà**. A ó da èyíkéyìí tí a bá fẹ́ fi pọntí sínú omi nínú ìkokò. Tí ó ba di ọjọ́ kejì, a ó wà á, a ó wa bù ú díẹ̀díẹ̀ sínú ̀igba-oko, a ó nà án fẹ̀lẹ̀fẹ̀lẹ̀ sí tí igbá-oko. A ó wá mu ewé ọ̀gẹ̀dẹ̀ tàbí ti **ògìrì-ìṣákọ́** tàbí ti làpálàpá, a ó fi bò ó, ó sì gbé e ka etí àjà. Tí ó bá di ọjọ́ kẹrin sí ọjọ́ karùn-ún, tí a bá yẹ̀ ẹ́ wò, a ó rí ipé ó ti hú dáadáa, wọn yóò ta egbò tí wọn yóò dìmọ́ ara wọn ṣìkìtì. Èyí ni a n pé ni **bọ̀tí**. Lẹ́yìn èyí, a ó da bọ́ti sínú ọlọ, a ó wẹ́ ẹ ṣàkàṣàkà, a kò nìí jẹ́ kí ó kunná rárá. Èyí ni **bọ̀tí wíwẹ́**. Tí a bá ṣe èyi tán, a ó da bọ̀tí ti a wẹ́ sínú ìkòkò, a ó bu omi sí i, a ó dá iná mọ́ ọn, yóo ma hó putuputu, a ó máa fi aláààdà rò ó lórí ààro. Aláààdà yìí ni ẹka ewé igi àgbọn àjànàkù ti a fi ń ṣe abẹbẹ̀. A ó gé ewé yìí tí kò fi níí ju bíi ẹsẹ̀ bàtà kan àbọ̀ sí ara ẹ̀ka yií. Èyí ni a ó ti bọ inú ìkòkò ọtí tí a ó máa fi rò ó. A ó wá tọ́jú koto kan tí a já ní ìdí róbótó, a ó to igi lé e nísàlẹ̀, a ó to kóríko lé e, a ó gbé e ka orí ìkòkò kan. A ó máa bu bọ̀tí tí a ti sẹ sínú koto yìí, omi rẹ̀ yóò sì máa ro sínú ìkòkò. Èyí tí ó wà nínú elékìtì, (koto tí a já ní ìdí) yìí ni a ń pè ni èèrí; èyí tí ó ro sínú ìkòkò ni ọtí ti a fẹ́ lò, òhun ni a ń pè ni **ọtí òjò**. Ọtí yìí yóò wà nínú ìkòkò fún bíi wákàtí mẹ́rin sí mẹ́fà. Ọtí yóò ti pa ojú dà lákòókò yìí, yóò dúdú kìrikìri; tí a bá tọ́ ọ wò, yóò mú lẹ́nu yàtọ̀ sí omi. Nígbà yìí ni a ó wá da ọtí sínú ìkòkò ńlá kan, a ó bẹ̀rẹ̀ sí ko iná mọ́ ọn gidigidi. Omi rẹ̀ yóò máa gbẹ, yóò sì máa mátè léti ìkòkò. Tí ó bá jinná dáadáa, a ó gbọ́n ọn kúrò lórí ààrò. Afẹ́fẹ́ yóò máa fẹ́ sí i. Tí ó bá tutù, a ó wa ọṣẹ ọtí tàbí ògúlúǹtu àlàpà ilé, a ó dà á síí lati fi 'dá' ọtí. A ó fi igbá kan bò ó mọ́ inú ìkòkò. Ọtí yóò wá ti darapọ̀, yóò máa hó kuṣu. Ó di kí á máa rọ ọ́ sínú agbé fún títà.

### 4.4.2.1 Ọtí Àgàdàǹgídí

Agbègbè tí ọ̀gẹ̀dẹ̀ bá ti pọ̀ ni a ti máa ń rí ọtí àgàdàǹgídí, ọtí àgbagbà. Kò wọ́pọ̀ kí á rí ẹni tí yóò máa ta ọtí yìí. Àwọn tí ọtí bá ń wù láti mu ni wọ́n máa ń dìídì ṣe ọtí yìí fún ìlò ara wọn. Ọtí yìí jẹ́ ọ̀kan lára ọtí tútù tí ó wà ní ilẹ̀ orùbá nítorí a kìí gbé e kaná tí yóò fi di mímu. Tí a bá fẹ́ ṣe ọtí yìí, ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà pípọ́n ni a ó ré sí wẹ́wẹ́ a ó sì kó o sínú omi. A ó bò ó mọ́lẹ̀ fún bí i ọjọ́ márùn-ún kí ó lè bà. Bí ó bá ti ń mú òórùn ọtí jáde, a jẹ́ pé ó ti fẹ̀ nìyẹn. Fífẹ̀ tàbí bíbà yìí ni ìgbà tí omi tí a bù lé orí ọ̀gẹ̀dẹ̀ bá ti yíra padà tó ti di ohun tó lè mú kí ojú èniyàn máa ta fírífírí, tó sì ti kan lẹ́nu.

### 4.4.2.2 Díẹ̀ lára Èdè Àmúlò fún Ọtí Pípọn

1. Bọ́tí : Ọkà tàbí Àgbàdo tí a ń gún láti fi ṣe ọtí
2. Díbà ọkà / àgbàdo: Bíbo ọkà àgbàdo mọ́ inú ooru kan láti lè mú kí ó kan dáadáa.

3. Èèrí : Pàǹtí tí ó máa ń kù nínú ajọ̀ nígbà tí a bá sẹ́ ọkà / àgbàdo tán
4. Ọtí fẹ̀ : Ìgbà tí ọtí àgàdàgídí bá kan dáadáa tó ń run ọtí
5. Ọtí òjò : Ọtí tí a kò díbà rẹ̀ tí a fi ń pọn ọ́n. À ń lò ó láti bọ òrìṣà lásìkò ilẹ̀ẹ́gbóná
6. Ọtí mú lẹ́nu : Ọtí tí a fi sí ẹnu tó jó ni lọ́nà ọ̀fun tàbí tí a rí ipa rẹ̀ lórí ahọ́n
7. Poóba : Fi nǹkan bo ọtí tí a díbà mọ́lẹ̀. Ohun tí a bò rẹ́jẹ́rẹ́jẹ́
8. Ọtí pípọn : Ọtí ṣíṣe ni à ń pè bẹ́ẹ̀.
9. Ọyá : Òhun náà ni ẹyá tàbí iyá
10. Ró ọtí : Dída òògùn tàbí àwọn ewé àti egbò igi kan sínú ọtí, kí ó lè baà le lẹ́nu.

## 4.5 Ìpín Karùn-ún

### 4.5.1 Ìkòkò Mímọ́

Bí a bá fẹ́ mọ ìkòkò, a ó lọ sí ilẹ̀ amọ̀, nítorí ilẹ̀ ni ó ṣe pàtàkì jù nínú ohun-èlò tí a fi ń mọ ìkòkò, èyí ni ilẹ̀ amọ̀, a ó lọ ṣá amọ̀, a ó sì rù ú wá sí ẹbu ìkòkò. Lẹ́yìn náà, a ó gún un lórí òkúta pẹrẹsẹ, nínú odó tàbí ni poro. Bí a ti n gún un ni a ó máa bu omi sí i, ti yóò fi mú bí iyan tí a fi akọ iṣu gún. Tí ó bá ti ri báyìí, a ó bẹrẹ sí i ṣù ú bí àkàṣù . ẹ̀kọ, a ó wá ṣu ọ̀kan yóò tóbi díẹ̀, èyí ni a ó fi pilẹ̀ irú ìkòkò, tí a bá fẹ́ mọ. Oríṣìí ni ìkòkò tí a le mọ́; a le mọ òdù ìkòkò, agbada, adípẹ tàbí ìdáná; a le mọ orù, ìsaasùn, ajere àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Tí a ó bá pilẹ̀ ìkòkò, a ó dojú irú ìkòkò tí a fẹ́ mọ délẹ̀, a ó fi omi tàbí eérú pa á lára, a ó wa máa fi amọ̀ ṣán an nídìí títí tí yóò fi yọ ọrùn díẹ̀. A ó fi èyí sílẹ tí yóò fi lera díẹ̀. Lẹ́yìn èyí, a ó ṣí i kúrò lára ìpìlẹ̀, a ó wá gbé e jókòó, ìdí rẹ̀ yóò sì rí bákan náà pẹ̀lú irú ìkòkò tí afẹ mọ, nígbà yìí ni a ó wá máa mú nínú amọ̀ kéékèèkéé ti a ṣù, a ó máa fi mọ ọn bọ̀ wá sókè títí tí yóò fi yọrùn tó bí a tifẹ̀ kí ó ga mọ, bí a ti ń mọ ọn yìí ni a ó máa fi òkúta dídan tí a ń pè ni aárẹ̀ bọ inú omi, a ó máa fi dán ìkòkò náà lóde àti nínú. Lẹ́yìn èyí, a ó ṣe etí ìkòkò yìí bí ó ti wù wá. Àkísà tútù ni a ó fi dán èyí. Lẹ́yìn èyí, a ó ṣe ọnà sí ara ìkòkò. Ọnà yìí ni a fi ń mọ pé Lágbájá báyìí ni o mọ ìkòkò yìí, a sì fi n mọ ẹbu ti ẹnìkejì. Kùùkù àgbàdo a mà wà lára èròjà tí wọ́n fi ń ṣe ọnà sí ara ìkòkò. Tí a bá ti ṣe ọnà yìí tán, a ó máa sá ìkòkò náà títí tí yóò fi gbẹ. Òjò kò gbọdọ̀ pa á lákòókò yìí.



Lẹ́yìn èyí, a ó sun ìkòkò. Tí a bá máa ṣe èyí, gbogbo àwọn tó ń mọ ìkòkò lẹbu yìí ni yóò dìjọ dáwọ́jọ ṣe é. Wọ́n yóò tọ́jú ọ̀pọ̀ kòríko gbígbẹ láti fi dá iná sun ìkòkò tí a ti mọ̀. Gbogbo àwọn ènìyàn yìí ni yóò kó ìkòkò ti wọn ni, tí ó ti gbẹ jáde. A ó kọ́kọ́ to koríko gbígbẹ tẹlẹ̀, a ó to igi wẹ́wẹ́ lé e lórí; a ó wá tó àwọn ìkòkò wọ̀nyí lé orí rẹ̀. lẹ́yìnnáà a ó kó koríko bo àwọn ìkòkò wọ̀nyí, yóò ga gèlètè. A ó wa sọ iná sí i, yóò sì jó kanlẹ̀ rẹ́úrẹ́ú. A ó ti tọ́jú èèpò irà, ṣàṣàǹgbà, igi ọ̀gbọ́lọ́, a ó gún wọn sí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Lẹ́yìn náà, a ó wa ihò kan bíríkótó, a ó to àpáàdì sínú rẹ̀ bí ìgbà tí a rẹ̀ ka-n-kéré, ibi ni a ó ti máa yí ìkòkò tí a bá ti yọ́ ọ sínú kòtò yìí, èyí ni a ń pè ní agbo ìkòkò. A ó wá tọ́jú igi tútù gígùn kan, a ó maa fi yọ ìkòkò jáde nínú iná, a ó máa fi igi yìí yí i lọ sí inú àgbo ìkòkò, a ó máa yi ìkòkò yí lọ sínú ẹbuníbi tí a ó ti máa tà á.

### 4.5.2 Àkíyèsí

Ohun tí a ṣe àkíyèsí tí a bá ń mọ ìkòkò ni pé, a kò gbọdọ̀ bá ọkọ ẹni jà, a kò sì gbọdọ ní ara ẹni sínú nídìí iṣẹ́ yìí nítorí kí Ìyámàpó le wáyé e're (Wo bí a ṣe ń ṣe òrí). Tí ìkòkò ènìyàn bá fọ́ púpọ̀ nígbà tí à ń sun ún, a ó fura sí irú ẹni bẹ́ẹ̀ pé ó ń lo inú méjì tàbí inú rẹ̀ kò mọ́. Ìyámàpó kò fẹ́ inú dúdú àfi inú kan. A kì í sábàá polówó ìkòkò. Ẹnití ó bá fẹ́ rà ni yóò lọ sí ẹbu tàbí ni ìsọ̀ ìkòkò ni ọjà. Tí a bá fẹ́ sun fitílà tàbí ìṣaasùn ọlọ́mọrí, nínú òdù ìkòkò, tí a já ìdí rẹ̀, tí a gbé ka orí ààrò ní a ó tò wọ́n sí, a ó wá dánásí abẹ́ rẹ̀ lẹ́yìntí fitílà ti a mọ bá ti gbẹ tán, a ó yí ohun náà nínú àgbo ìkòkò bí ti àwọn ìkòkò ńlá ìyókù.

Àkíyèsí mìíràn tún ni pé, iṣẹ yìí kò fẹ́ rí ẹni yà sí ìdí rẹ̀ mọ lóde òní, àwọn ohun tó fa sábàbí èyí tó bí i mélòó kan. Tí a bá wò ó dáadáa lóde òní , àwọn iléeṣẹ́ tó ń ṣe àwọn ohun èlò bí i rọ́bà, garawa ayọ́, ìkòko irin , àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, kò je kí ìkòkò mímọ dìde sókè mọ́. Gbogbo àwọn ohun èlò tí a dárúkọ wọ̀nyí ló ń ṣe iṣẹ́ tí ìkòkò ń ṣe. Wọ́n ń ṣe èyí tó jọ orísìríísì ìkòkò lẹ́jẹ́wọ̀nlẹ́jẹ́wọ̀n, èyí ko jẹ́ kí ìkòkò mímọ gbajúmọ̀ mọ ní ayé òde òní. Púpọ̀ àwọn ọmọ òde òní ni kò tilẹ̀ mọ ohun tí ó ń jẹ ìkòkò ,

kí á ma tilẹ̀ máa sọ pé kí wọ́n mọ ìwúlò rẹ̀. Ìwádìí tí àwọn dókítà onímọ̀ iṣègùn òde òni ṣe ní àìpẹ́ yìí fihàn pé, ọbẹ̀ tàbí oúnjẹ tí a bá sè ninú ìkòkò amọ̀ ṣe ara lóore ju èyí tí a bá sè nínú rọ́bà oúnjẹ, ike, tàbi abọ ayọ́ lọ. Èyí já sí pé àwọn babańla wa náà lo ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì láti mọ ìkòkò kí ó lè ṣe ara wa lóore, tí a bá sì tún ṣe àkíyèsí, ọbẹ̀ àti oúnjẹ tí a bá sè nínú ìsaasùn kìí tètè tutù rárá. Ohun tí à ń sọ ni pé ó yẹ kí á gbìyàjú láti lo ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì àti ìmọ̀ ẹrọ ti òde òní láti tẹ̀síwájú ní ibi tí àwọn babańlá wa bá a dé. Kí a lo ẹrọ ìgbàlódé láti fi mú ki ìkòkò mímọ rọrùn, kí ó ní àlòpẹ́, kí á sì ṣe àgbédìde rẹ̀ lọ́nà tí yóò tún mú kí ètò ọrọ̀ ajé orílẹ̀ède wa rú gọ́gọ́ sí i, nígbà tí a bá sọ iṣẹ́ ìkòkò mímọ yìí di ti ìgbàlódé tí à ń tà sí Òkè- Òkun. Ohun tí eléyìí yóò ṣe ni pé, yóò mú àgbéga bá èdè àti àṣà Yorùba, yóó sì tún pèsè iṣẹ́ fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ọ̀dọ́ tí kò ní iṣẹ́ lọ́wọ́

### 4.5.3 Díẹ̀ Lára Èdè Àmúlò fún Ìkòkò Mímọ

**1. Ajere** : Oríṣi ìkòkò kan tí wọ́n máa ń fi ìlu dá ihò sí lára fórofòro
2. Gbájù : Koríko ọ̀sẹ́pòtu tí wọn máa ń dì pọ̀ láti wọ́n omi sí ara ìkòkò
3. Ìdé Dídé: Ìbẹ̀rẹ̀ ìkòkò mímọ ni èyí, bí wọ́n bá bu amọ̀ , wọn yóò fi ẹsẹ̀ tẹ̀ ẹ́ kó lè rí fèrègẹ̀dẹ̀ , èyí ni wọ́n máa ń gbé láti fi ṣe òdiwọ̀n ìkòkò tí wọ́n fẹ́ yọ
4. Pamọ́pamọ̀ : Igi pẹlẹbẹ tí wọ́n fi ń gbá etí apẹ kó lè fún pọ̀ díè.
5. Igbó Amọ̀ : Ibi tí àwọn amọ̀kòkò ti lọ ń wá amọ̀
6. Igi Ìrà : Oríṣi igi kan tí wọ́n máa ń lo omi rẹ̀ láti ju ìkòkò lára bí wọ́n bá sun ún tán.
7. Fífá etí Apẹ : Èyí ni lílo ewé làpálàpá láti fi dán etí ìkòkò
8. Awẹ̀ Orìṣà : Àwo amọ̀ kékeré tí a fi ń pèsè sídìí òrìṣà tàbí tí a fi ń gbé ẹbọ
9. Ìbà ṣíṣe : Àtòpọ̀ àwọn nǹkan tó lè mú kí ìkòkò tàbí ohunkóhun tí a bá ń mọ ní ẹbu ga sókè tí amọ̀kòkò kò fi níí máa bẹ̀rẹ̀ púpọ̀ láti ṣe iṣẹ́ rẹ̀. Ó lè jẹ́ ìkòkò tí kò ṣe é dáná mọ́, odó iyán tàbí àjákù garawa
10.Àwo amọ̀ : Kinní kan báyìí tó tẹ́jú pẹrẹsẹ tí à fi ń gbé oúnjẹ fún onílé àti àlejò ní ayé àtijọ́ kí àwo tánńganran àti abọ́ tó dé
11. Ìkòkò pa : Apẹ tó bá fọ́ lẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí ní ibìkan lásìkò tí a bá ń sun ún
12. Pamọ̀pamọ̀ : Igi tàbí pákó pẹlẹbẹ tí a fi ń gbá apẹ létí kí ó lè kájú kò díẹ̀ kí a tó sá a gbẹ
13. Ìkòkò ta : Ìkòkò tí òkúta kékeré bá yọ kúrò lẹ́gbẹ̀ẹ́ rẹ̀ lẹ́yìn tí a ti sun ún tán.
14. Òòrun : Okùn kékeré kan tí a lọ́ pọ̀ bíi okùn ẹran láti fi ré ara ìkòkò lẹ́yìn tí a bá yọ ọ́ tán. Èyí ni kìí jẹ́ kí ara ìkòkò dán bọ̀rọ́bọ̀rọ́, èyí tó lè jẹ́ kó yọ̀ jábọ́ lọ́wọ́ ènìyàn.
15. Kete : Òhun náà ni Ládugbó. Ohun èlò tí wọn fi ń pọn omi lódò láyé àtijọ́ kí péèlì tó dé
16. Ojú Odó : Ibi tí a ti máa ń gún amọ̀ ní ẹbu ìkòkò ni à ń pè bẹ́ẹ̀

17. Orù : Ohun èlò kékeré kan báyìí tí a fi ń rọ omi nídìim òrìṣà tàbí tí a máa ń lò láti fi se àgbo. Òhun náà jọ kete.
18. Ṣágo : Ohun èlò tí ẹnu rẹ̀ kéré tó sì ní ọrùn gígùn èyí tí ọwọ́ àgbàlagbà kò lè wọ̀. Ó fi ọrùn àti ẹnu jọ akèrègbè
19. Ìkòkò olóṣooṣo : Ìkodkò tí ó fi ara jọ ajere, èyí tí àwọn aláró àti ọlọ́ṣẹ máa ń lò láti ṣẹ̀dá omi aró láti ara eérú
20. Ìkòkò bọ́ọre : Kò sí iṣòro ní àsìkò tí a sun ìkòkò nínú iná. Ọ̀jò kò rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni apẹ kò pa.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Ní ìpín Kẹta yìí , a ti kà nípa onírúurú iṣẹ́ ẹbu ní ilẹ̀ Yorùbá. A ti gbìyànjú láti ṣàlàyé gbogbo wọn níkọ̀ọ̀kan, bí a ṣe ń ṣe wọ́n, díẹ̀ lára àwọn èròjà tí à ń lò àti ìwúlò wọn. Bákan náà ni a sọ díẹ̀ lára àwọn èdè àmúlò tí a máa ń gbọ́ nídìí àwọn iṣẹ́ yìí

**Iṣẹ́ Ṣíṣe**

(i) Dárúkọ méjì lára àwọn ohun-èlò tí a fi ń mọ ìkòkò.
(ii) Ṣe àlàyé ìwúlò irú.
(iii) Ǹjẹ́ Aró dídá ṣì wúlò lóde òní, ṣàlàyé?
(iv) Kọ kí o sì ṣàlàyé márùn-ún lára àwọn èdè àmúlò ìkòkò mímọ

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasi

Adéoyè, C.L. 2005. *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Limited

Dáramọ́lá. O àti Jẹ́jẹ.A. 1968. *Àwọn Àṣà Àti Òrìṣa Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press

Ílésanmí, T.M. 1989.*Ìṣẹ̀ǹbáyé*. Ilé-ifẹ̀, University of Ife Press.

Ládélé, T.A.A, et.al. 2006 *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn Gavima Press Ltd.

Ọlájubù, O. 2011. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ìkẹjà, Lagos: Longman Nigeria Plc

# MÓDÙ KẸRIN IṢẸ́ YORÙBÁ NÍ AYÉ ÒDE-ÒNÍ

## 4.0 Ìfáárà

Ohun tí Módù kẹrin yìí dálé, tí o ó kà nípa rẹ̀ ni àwọn iṣẹ́ tí ó wà ní ayé òde-òní tí à ń fi ọgbọ́n ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìwé tí a kà ṣe, pàápàá ìmọ̀ ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá. Nínú Módù yìí ni ó ti máa kà nípa àwọn iṣẹ́ mélòó kan tí a lè fi ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá ṣe. Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe mọ̀ pé lóde òní, ọ̀làjú ti mú kí àwọn ènìyàn pàápàá jùlọ àwọn ọ̀dọ́ ìwòyí sún sẹ́yìn fún àwọn iṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìwọ̀nba péréte ni àwọn tó ṣì ka àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé sí. Báyìí, ọ̀làjú ti dé, nǹkan sì ti yípadà sí ti tẹ̀lẹ̀, nítorí náà ni a ó ṣe tanná wádìí àwọn iṣẹ tí a lè ṣe lóde òní. Nínú Módù yìí, ìwọ yóò kà nípa iṣẹ́ Olùkọ́, Olúyoko, Alága igbéyàwó, Ògbufọ̀, àti àwọn mìíràn.

## 4.1 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà olùdánilẹ́kọ̀ọ́ fún ọ ni kí o mọ díẹ̀ lára oríṣi àwọn iṣẹ́ tí o lè ṣe pẹ̀lú ìmọ̀ ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá tí ò ń kọ́ nípa rẹ̀. Kí o sì mọ̀ bí o ṣe lè gbáradì fún èyíkéyìí tí o bá yàn láàyò.
Pẹ̀lú àfojúsùn pé ìwọ yóò lè ṣe iṣẹ́ náà ní ibikíbi tí o bá bá ara rẹ, o ó sì lè kọ́ ẹni yòówù tí ó bá nílò ìmọ̀ rẹ lórí iṣẹ́ tí o yàn láàyò.

## 4.2 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Dárúkọ oríṣi Olùkọ́ méjì
2. Sọ mẹ́ta nínú ohun ti Olúyoko gbọ́do jẹ́
3. Ta ni Ògbufọ̀
4. Ṣàlàyé mẹ́ta nínú ohun tí ògbufọ̀ gbọ́dọ jẹ́
5. Ṣàlàyé ẹyọ kan nínú ohun tí alága igbeyàwó gbọ́dọ̀ mọ̀ ṣe

## 4.3 Ìpín Kìiní : Olùkọ́

### 4.1.1 Iṣẹ́ Olùkọ́

Olùkọ ni ẹni yòówù tí ó ń kọ́ ní ní ẹ̀kọ́, tí ó ń fi òye iṣẹ́ yé ni, tí ó sì ń tọ́ ni sọ́nà. Tí a bá yiiri oríkì yìí wò dáadáa a ó rí i pé ẹni tí a bá pè ní olùkó gbọ́dọ̀ jẹ́ eni tí ó ní ìmọ̀ ju ẹni tí ó ń kọ́ lẹ́kọ̀ọ́ lọ. Ní ilé ayé yìí òbí ọmọ ni olùkọ́ àkọ́kọ́ fún ọmọ, gbogbo ohun tí òbí bá ń ṣe ni ọmọ yóò máa wò, bẹ́ẹ̀ náà ni yóò sì máa tẹ́tí sí ìtọ́ni láti ọdọ̀ òbí. Lẹ́yìn òbí ọmọ ni ó kan olùkọ ilé-ẹ̀kọ́ tí ọmọ ń lọ, èyí ni olùkọ kejì. Kìí ṣe ọ̀rọ̀ ẹnu nìkan ní olùkọ́ ń lò láti fi kọ́ni, ìwà àti ìṣe olùkọ́ ṣe pàtàkì sí akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀. Iṣẹ́ tí olùkọ ń ṣe nínú ìdàgbàsókè akẹ́kọ̀ọ́ kò kéré rárá, láti kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ láyé òde òní kìí ṣe jíjókòó sínú yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ nìkan mọ́, nítorí ayétilujára nípa ìmọ̀ ẹrọ kọ̀ǹpútà. Bí o bá diakẹ́kọ̀ọ́gboyè nínú èdè Yorùbá o lè ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ láti ibikíbi tí o bá wà, kí o sì máa kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ rẹ ni apá ibi yòówù kó jẹ́ lágbàáyé. A ti rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ tí wọn ń fi ẹ̀kọ́ èdè àti àṣà Yorùbá kọ́

àwọn tí ó wà ní ìlú òyìnbó, tí wọ́n sì ń rí owo gọbọi làti ibẹ̀. Yàtọ̀ sí àwọn ti ó wà ní òkè-òkun, gbogbo ibi ni ọwọ́jà ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà dé, ó sì ti mú kí iṣẹ́ olùkọ́ rọrùn púpọ̀. Láti jẹ́ olùkọ́ èdè tí ó bá ìgbà mu, o gbọ́dọ̀ lè:

1. Kàwé gboyè lóri èdè Yorùbá
2. O gbọ́dọ̀ ní ìmọ̀ ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà
3. O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó nífẹ̀ẹ́ sí àtimáa gbọ́ ìròyìn nípa ohun tó ń lọlágbàáyé
4. O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tó lè kọ́ni pẹ̀lú ìfarabalẹ̀
5. O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó fẹ́ràn ọmọdé
6. O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí kanra
7. O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tó ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run

## 4.2 Ìpín Kejì

### 4.2.1 Olúyoko

Olúyoko ni adarí ètò níbi àríyá tàbí ayẹye. Bí a ti ṣe mọ̀ pé ìran Yorùbá jẹ́ ìran tí kìí ṣe ọ̀lẹ, wọ́n fẹ́ràn láti máa ṣiṣẹ́, lẹ́yìn tí wọ́n bá sì siṣẹ́ tán, fàájì ló kàn. Nítorí náà tí wọ́n bá gbé ayẹyẹ kalẹ̀, àwẹ̀jẹwẹ̀mu máa ń pọ̀, wọ́n á fi ilé pọn ọtí, wọn a fi gbogbo ọ̀nà rokà, wọn á sì fi gbogbo agbada dín ẹran, tí àwọn ènìyàn yóó sì jẹun tẹ́rùn. Wàyí o, kí ayẹyẹ baà lè ní ètò tí à ń tẹ̀lé, kí gbogbo rẹ̀ má di rúdurùdu, ni a fi nílò iṣẹ́ Olúyoko. Iṣẹ́ olúyoko ni láti ṣe àlàkalẹ̀ ètò tí àwọn ènìyàn yóò tẹ̀lé ní ibi ayẹyẹ. Ara iṣẹ́ rẹ̀ ni láti fi àwọn àlejò pàtàkì hàn, kí ó sì pè wọ́n sí orí ìjókòó tí wọ́n ti ṣètò sílẹ̀. Iṣẹ́ olúyoko náà ni láti rí i dájú pé, ibi tàbí gbọ̀ngàn àríyá dùn pẹ̀lú ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ àwàdà tí yóò máa pa àwọn ènìyàn lẹ́rìn-ín.

Ní àwùjọ wa lónìí, púpọ̀ ènìyàn ló ń ṣiṣẹ́ olúyoko, àwọn tí kò tilẹ̀ kọ́ ẹ̀kọ́ èdè, ṣùgbọ́n tí wọ́n ní ẹ̀bùn sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ máa ń ṣiṣẹ́ olúyoko, Ẹni tí ó bá tún wá kọ́ ẹ̀kọ́ èdè tí ó sì tún ní ẹ̀bùn sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀, àrà ọ̀tọ̀ ni iṣẹ́ olúyoko tirẹ̀ yóò jẹ níbi ayẹyẹ tí wọ́n bá pè é sí. Iṣẹ́ olúyoko yìí jẹ́ iṣẹ́ tí púpọ̀ àwọn tí wọ́n ti kẹ́kọ̀ọ́ gboyè nínú èdè Yorùbá yàn láàyò, nítorí abala ẹ̀kọ́ nípa lítíréṣọ̀ àti àṣà jẹ́ ìrànlọ́wọ́ láti ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bíi olúyoko. Láti jẹ́ olúyoko, o nílò láti mọ àwọn nǹkan wọ̀nyí:

- O gbọ́do mọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ òwe àti àkànlò èdè
- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tó mọ àṣà àti ìṣe Yorùbá
- O gbọ́dọ̀ lè ki oríkì ìlú, oríkì orílẹ̀, oríkì àwọn bọ̀rọ̀kìní àti àwọn oríkì mìíràn
- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó mọ̀ nípa orin ìbílẹ̀ àti ti ìgbàlódé, kí o sì lè mọ̀ àsìkò tí wọ́n wúlò
- O gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa èto ìṣèlú àti ọ̀rọ̀ tó ń lo ní àwùjọ
- O gbọ́dọ̀ gbìyànjú láti ṣe ìwádìí sílẹ̀ nípa àwọn tí wọ́n gbà ọ́ ní olúyoko. Èyí ni mímọ ọmọ ìlú tí wọ́n jẹ́, oríkì wọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Tí ó bá ṣeéṣe, kí o mọ ti àwọn àlejò pàtàkì tí wọ́n pè sí ibi ayẹyẹ náà
- O gbọ́dọ̀ lè sọ̀rọ̀ dáńtọ́, kí o sì mọ èdè Yorùbá lò bí ó ti tọ́
- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó ní ọ̀yàyà

- Ìmura rẹ gbọ́dọ̀ jẹ́ ti ọmọlúàbí, kó wú ni lórí, kó sì fi ọ́ hàn bíi ẹni àpọ́nlé
- O kò gbọdọ̀ fi ẹ̀sìn kankan hàn bí i ààyò rẹ tí o bá ń ṣiṣẹ́ olúyoko.

### 4.2.2 Alága Ìgbéyàwó

Àwọn alága ní ibi ìgbeyàwó ni àwọn tó máa ń gbẹnusọ fún ìdílé, yálà ìdílé ọkọ tàbí ti ìyàwó. Láyé àtijọ́, àwọn ìyàwó tàbí obìnrin ilé ló máa ń ṣe ojúṣe yìí, ṣùgbọ́n ní báyìí, tí ayé ti di ayé ọ̀làjú, gbogbo nǹkan ló ti yípadà, ẹnikẹ́ni ló lè sọjú ẹbí ìyàwó tàbí ẹbí ọkọ, dandan sì kọ́ ni kí irú ẹni bẹ́ẹ̀ mọ ẹbí tí ó fẹ́ ṣoju wọn tẹ́lẹ̀.Ohun tí ó ṣe pàtàki ni kí alága ìgbéyàwo ti mọ gbogbo bí wọn ṣe ń ṣe é ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé. Tọkùnrin ,tobìnrin ló ń ṣe alága ìgbeyàwó lóde òní, owó ni wọ́n sì fi ń pè wọ́n láti ṣiṣẹ́ yìí, nítorí wọ́n ti mú un gẹ́gẹ́ bí i iṣẹ́ òòjọ́ wọn. Bí alága bá ṣe jáfáfá sí ni yóò sọ bí ètò ìdána náà yóò ṣe dùn tó. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́gboyè nínú èdè Yorùbá lè ṣe iṣẹ́ yìí , nítorí ẹ̀kọ́ èdè àti àṣà tí wọ́n ti ní òye rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bíi alága ní ibi ìgbeyàwó, ó yẹ kí o lè ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí:



- O gbọ́dọ̀ lè kọ orísiríìṣi orin
- O gbọ́dọ̀ mọ nípa àwọn àṣà ilẹ̀ Yorù**bá, pàápàá** àṣà ìgbeyàwó
- O gbọ́dọ̀ mo ijó jó dáadáa
- O gbọ́dọ lè ki oríkì ìdílé àti oríkì ìlú ọkọ àti ti ìyàwó
- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tó ní ọ̀yàyà , tí kìí fajúro
- O gbọ́dò mọ ọ̀rọ̀ sọ dáadáa
- O gbọ́dò lè ṣe àwàdà díẹ̀
- O sì gbọ́dọ̀ múra dáadáa pẹ̀lú aṣọ tó jíire

## 4.3 Ìpín Kẹta

### 4.3.1 Ògbufọ̀

Ògbufọ̀ ni ẹni tó ń gbìyànjú láti yí èdè kan padà sí èdè mìíràn. Akitiyan tàbí ìgbìyànjú ògbufọ̀ láti yí èdè kan padà sí èdè mìíràn ni à ń pè ní aáyan ògbufọ̀. Onírúurú ni ọ̀nà tí ògbufọ̀ fi wúlò láyé òde òní, lára rẹ̀ ni, yíyí ìwé láti èdè kan sí èdè mìíràn, ṣíṣe àyípadà àkọsílẹ̀ ìpàdé sí èdè mìíràn, yíyí àwọn ọ̀rọ̀ àpilẹ̀kọ padà sí èdè mìíràn, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
Àwọn Àmúyẹ ògbufọ̀ :

i Gẹ́gẹ́ bíi ẹni tó kọ́ ẹ̀kọ́ èdè, ògbufọ̀ gbọ́dọ̀ lè sọ, kí ó sì gbọ́ èdè méjéèjì dáadáa, èyí ni èdè tí ó ń gbufọ̀ rẹ̀ àti èyí tí ó ń gbufọ̀ sí
ii Ó gbọ́dọ lè ṣe àyípadà láìsọ ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ nù
iii Ó gbọ́dọ̀ mọ àwọn òwe àti àkànlò èdè tí yóò ṣe rẹ́gí
iv Ó gbọ́dọ̀ mọ ìyàtọ itumọ̀ ìjìnlẹ̀ àti ìtúmọ̀ lérèfẹ̀é

ohun mìíràn tó tun se Pataki ni pe, ẹni ti yoo ṣe aayan ogbufo gbọ́dọ̀ mọ àkọtọ́ ati sípélì èdè mejeeji. O gbodo mọ̀ nipa àṣà ati ìṣe ede méjèèjì. Idi ni pé a kò lè fi agbada èdè kan dín ẹran òmíràn; ede kọọkan ló ni òfin àkọtọ́ ati aṣa ajẹmédè rẹ̀. Yato si eyi, eni ti yoo se aayan ogbufo gbodo ni ìwé atúmọ̀-èdè ati iwe èdè-iperí ede mejeeji. O gbodo maa ka iwe deedee nitori pe 'ọgbọ́n ọdún yii, wèrè ẹ̀míì ni'. Ìmọ̀ nipa ede kò duro sójú kan, ojoojumo ni ọgbọ́n ìmọ̀ ede ń sún siwaju.
Owó tabua ló wà ninu iṣẹ́ ogbufo. Bi apeere, ni asiko ìpolongo ìbò, awon olóṣèlú maa ń nílò awon tó dánńtọ́ ninu ede lati bá wọn ṣe ògbufọ̀ lati ede kan si omiran ki awon ara ilu, paapaa, awon oludibo le gbọ́ won ni àgbọ́yé. Ni awon ile ijosin bii Soosi ati Mosalasi, àwọn ogbufo lo maa n tumo ede kan si omiran. Eni ti yoo se eyi gbodo je eni ti ara rẹ̀ balẹ̀ to si maa ń tẹ́tí si ohun ti elomiran n sọ ko le gbọ́ ọ ní àgbọ́yé.

### 4.3.2 Iṣẹ́ Oníròyìn

Àwọn oníròyìn ni wọ́n máa ń fi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ohun tí ó ń lọ ní àwùjọ tó àwọn ará ìlú létí, nípa ṣíṣe àmúlò àwọn ohun-èlò tàbí ẹ̀rọ ìbáraẹnisọ̀rọ̀ bíi tẹlifíṣàn, rédíò, ìwé ìròyìn àti ẹ̀rọ ayélujára. Yàtọ̀ sí ṣíṣe ìròyìn, àwọn oníròyìn máa ń kọ́ ni lẹ́kọ̀ọ́, nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n ń ròyìn rẹ̀, tí ó jẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ, wọ́n sì máa ń dá àwọn ará ìlú lára yá nípa àgbéjáde àwọn ètò amúlùúdùn lórí rédíò tàbí tẹlifíṣàn; ó sì lè jẹ́ nípa kíkọ àwọn ọ̀rọ̀ efẹ̀ síta nínú ìwé ìròyìn tàbí magasínnnì. Eni to ba fe sise oniroyin gbodo já fáfá, o gbodo mo ede Yoruba ko, ki o si mọ̀-ọ́n sọ daadaa. Idi ni pe ede ni irin iṣẹ́ gbòógì ti oniroyin nilo. A ni awon oniroyin to maa ń lọ kaakiri lati gba awon iroyin ohun to n lọ lawujo nipa lílọ síbi awon iṣẹ̀lẹ̀ ó-ṣojú-mi-pàtó tabi awon iṣẹ̀lẹ̀ yàjóyàjó. Bi oniroyin naa ba ti dé ibi isele naa, ó gbodo ṣe akọsílẹ̀ ohun tó ṣẹlẹ̀, idi to fi ṣẹlẹ̀, bí isele naa ṣe sẹlẹ̀, ati awon ohun to ṣe okùnfà isele naa. Leyin naa ni yoo mu iroyin naa lo si ile-ise re ki awon ti a mọ̀ si olótùú le ṣe àyẹ̀wò iroyin naa kó tó lọ sí orí afẹ́fẹ́ tabi di títẹ̀ jade sinu ìwé ìròyìn

Iṣẹ́ Oníròyìn àti ògbufọ̀ súnmọ́ ara wọn, nítorí ọ̀pọ̀ ìgba ni akàròyìn yóò ní láti ṣe àyípadà èdè kan, sí èyí tí ó fẹ́ kà. Ẹni tí ó jáfáfá tí ó sì gbọ́ èdè yékéyéké, tí ó dáńtọ́, tí kìí sọ̀rọ̀ dìẹ̀dìẹ̀ ló lè jẹ́ oníròyìn. Yóò nílò láti gbá ìròyìn jọ káàkiri, yóò ṣe àkójọpọ̀ ìròyìn, ó sì lè nílò kó ṣe ògbufọ̀ ìròyìn tí ó gbà, kó tó di pe yóò di kíkà. Ẹni tó bá gbọ́ èdè Yorùbá dáadáa tó sì ní ìmọ̀ tó kún nípa èdè ló lè ṣiṣẹ́ oníròyìn.

Ní ayé òde-òní, akẹ́kọ̀ọ́jáde le da ile- ise iroyin tire sile lai si labe enikeni. Orisirisi awon ikànnì abánidọ́rẹ̀ẹ́ lo wa lori ìtàkùn àgbàyé ti oniroyin igbalode le se amulo won. Ṣùgbọ́n, awon ofin kan wà to de iṣẹ́ oniroyin. Bi apeere, a ko gbodo gbe iroyin òfeegè jade rara; a ko gbodo se agbekale iroyin lọ́nà ti yoo fi dá ipayà sọ́kàn awon ara ilu; a ko gbodo se iroyin ti yoo da omi alaafia ilu tabi agbegbe ru. Eni to ba fe se ise oniroyin gbodo nífèé si iwe kika daadaa. Ó gbodo gbójú, gbónu, ki o sì gbóyà. Ede Yoruba gbodo dá múṣémúṣe lẹ́nu rẹ̀. Bo ba si je eto idanilaraya ni a fe yan laayo lori redio tabi telifisan, gbogbo re lo ni ètò. A ni lati ni afojusun ohun ti ètò naa yoo da le. O le da lori asa, ìṣe tabi eto awujo, o si le dá lé ori oro to ń lọ lawujo bii igbeyawo, esin, asọ wiwọ̀ tàbí orin. Ohun to ṣe Pataki ni pé eto naa gbodo danilekoo tabi ki o da ni laraya. Lori redio ati telifisan, a ki i sọ awon ọ̀rọ̀ àlùfànǹsá tabi ki a so ohun to le tabuku bá ijoba. Ti akekoo-jade Ede Yoruba ba nifee si ise iroyin, o le tún kẹ́kọ̀ọ́ sí i nípa iṣẹ́ naa lọ́dọ̀ awon ajo tí a mọ̀ si Nigeria Institute of Journalism

### 4.3.3 Ọ̀ṣèré Orí ìtàgé

Yàtọ̀ sí níní ẹ̀bùn láti ṣeré, ẹni tó fẹ́ jẹ́ òṣèré gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó gbọ́ èdè jinlẹ̀, kó sì lè sọ ọ́ dáadáa, pàápàá ẹni tí ó bá jẹ́ òṣèré tó ń lo èdè Yorùbá, kò yẹ kí ó máa sọ àmúlùmálà èdè lórí ìtàgé. Ìdí nìyìí tí ó fi jẹ́ pé , àwọn tí óbá gbọ́ èdè, tí wọ́n kẹ́kọ̀ọ́ gboyè nínú èdè Yorùbá ló kún ojú òṣùwọ̀n láti jẹ́ òṣèré.

Eré orí ìtàgé níí ṣe pẹ̀lú lílo ọgbọ́n àtinúdá láti dá àwọn òǹwòran lárayá adti láti kọ́ wọn lẹ́kọ̀ọ́. Ẹni tí yóò jẹ́ òṣèré orí ìtàgé gbọ́dọ gbójú gbóyà, kó sì mọ bí a ti í ṣe ìfidwàwẹ̀dá. Ó gbọ́dọ̀ ní ẹ̀bùn ìrònújinlẹ̀ láti le kó ipa tí yóò ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ẹ̀dá-ìtàn tí wọn ní kí ó kó ipa rẹ̀. Ní ẹ̀ka eré orí ìtàgé, a led yàn láti je adarí eré tàbí amojú ẹ̀rọ, ṣùgbọ́n àwọn ti ó jẹm òṣèré ló máa ń gbajúmọ̀ jù. Àmúlò ẹ̀rọ ìgbàlódé tí jẹ́ kí iṣẹ̀ àwọn òsèré orí ìtàgé gbajúmọ̀, nítorí ayé ti di ayé fìimù àgbéléwò. Bí a bá ya fíímù , tó dára , tí ó sì jẹ́ ohun tí àwùjọ tẹ́wọ́ gbà, ẹni tí ó ni fíímù lè ti ibẹ̀ di olówo tabua. Púpọ̀ àwọn òṣèré orí ìtàgé tí wọn ń ṣe fíímù àgbéléwò báyìí ní àwùjọ wa ni wọ́n ti di ìlú-mọ̀-ọ́n-ká nídìí iṣẹ́ náà, tí wọn sì ń lọ sí orílẹ̀èdè káàkiri, pàápàá jùlọ Òkè-òkun bí ẹni lọ sí ọjà etílé ni.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, ẹni tí yóò ṣe eré orí ìtàgé gbọ́dọ̀ ní ebùn àtinúdá nípa ìfidwàwẹ̀dá, bí àpẹẹrẹ tí ó bá ṣe olówó nínú eré kan, bí wọ́n bá ní

kó tún kó ipa ẹni tó ya wèrè nínú eré mìíràn ó gbọ́dọ̀ lè ṣe é débi pé àwọn òǹwòran yóó ti gbàgbé pé eré lásán ni wọ́n ń ṣe, ó gbodo¸dàbí ẹni pé wọ́n ń wo wèrè lójú ayé ni.

**Àwọn Àmúyẹ Òṣèré Orí Ìtàgé**

1. Aṣa Yorùbá : Láti lè ṣe àṣeyege nínú iṣẹ yìí , ò di dandan kí òṣèré ní ìmọ̀ tó jinlẹ̀ nínú àṣà, ìṣe àti ìtàn Yorùbá. Bí adpẹẹrẹ, àṣà ìwọṣọ, àṣà ìgbeyàwó, àṣà ìsọmọlórúkọ, àsà ìsìnkú, ìtàn nípa orírun ìlú kọ̀ọ̀kan ní ilẹ̀ Yorùbá, àti bẹ́ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn àṣà yìí ni yóò máa dàbí orísun ìmọ̀ nínú èyí tí yóò máa ṣe àmúlò ọgbọ́n àti èròjà erté gbogbo tí ó nílò
2. Èdè Yorùbá : Òṣèré gbọ́dọ̀ dáńtọ́ nínú èdè Yorùbá, kí ó gbọ́, kí ó mò ọ́n sọ, kí ó lè kọ ọ, kí ó sì lè kà á . Ẹni tí ó bá nífẹ̀ẹ́ sí iṣẹ́ yìí lè máa wo àwọn fíímù àgbéléwò tí wọ́n ti ń sọ àwọn ìjìnlẹ̀ Yorùbá, èyí yóò jẹ́ kí mùṣèmúṣè rẹ̀ dá múṣémúṣé
3. Ṣíṣe Àwòkọ́ṣe : Ẹni tó bá fẹm gbajúmọ̀ nínú eré orí ìtàgé gbọ́dọ̀ máa wo àwòkọ́ṣe àwọn ará iwájú, kí ó máa wo bí wọ́n ṣe ń ṣe , kí òun pẹ̀lú lè dáńgájíá nínú iṣẹ́ náà
4. Àmúlò ẹ̀rọ ìgbàlódé : àmúlò ẹ̀rọ ìgbàlódé ṣe pàtàkí fún eré orí ìtàgé lóde òní. Àwọn ìkànnì ìbánidọ́rẹ̀ẹ́ ni àwọn tó ní ẹ̀bùn eré ṣíṣe ti ń ju àwọn fọ́nrán iṣẹ́ wọn sí àwùjọ, èyí tí ó sì ń mú owó wọlé fún wọn lóòrèkóòrè.

Yíyan iṣẹ́ tíátà lááyò ní àǹfàání púpọ̀, yàtọ̀ sí pé èniyàn yóò gbajúmọ̀ ní àwùjọ, owó wà níbẹ̀ fún ẹni tí ó bá kọ fíímù. Jíjẹ́ aṣojú àwọn ileeṣẹ́ ńláńlá, jíjẹ àǹfàání lílọ sí òkè-okun , parípari rẹ ni pé, emìyàn lè dá iṣẹ́ tíátà ti ara rẹ̀ sílẹ̀ tí yóò sì gbà òṣìṣẹ sì i.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Ní ìpín kẹrin yìí, a ti ṣàlàyé nípa àwọn iṣẹ tí a lè fi ẹ̀kọ́ ìmọ̀ èdè Yorùbá ṣe lóde òní. A ṣàlàyé iṣẹ́ olùkọ́, Olúyoko, Alága ìgbéyàwó, Ògbufọ̀, Oníròyìn àti Òṣèré orí ìtàgé. A jíròrò lórí ohun tí ẹni tí ó bá fẹ́ ṣe iṣẹ́ wọ̀nyí gbọ́dọ̀ mọ̀, kí wọ́n sì lè ṣe. Ìgbàgbọ́ mi mi pé ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ ti ní òye àwọn iṣẹ́ náà, àti èyì tí o nífẹ̀ẹ́ sí láti yàn lááyò.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Sọ mẹ́rin lára ohun tí olùkọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́
ii. Ko àwọn iṣẹ́ mìíràn tí a lè fi ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá ṣe yàtọ̀ sí àwọn tí a dárúkọ lábẹ́ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí
iii. Ta ni Ògbufọ̀?
iv. Ṣàlàyé lẹ́kùn-ùnrẹ́rẹ́ lórí Olúyoko

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adéoyè, C.L. 2005. *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Limited

Dáramọ́lá. O àti Jẹ́jẹ.A. 1968. *Àwọn Àṣà Àti Òrìṣa Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press

Ílésanmí, T.M. 1989.*Ìṣẹ̀ǹbáyé*. Ilé-ifẹ̀, University of Ife Press.

Ládélé, T.A.A, et.al. 2006 *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn Gavima Press Ltd.

Ọlájubù, O. 2011. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ìkẹjà, Lagos: Longman Nigeria Plc